


Scanned with CamScanner

ETO ỌSẸ ỌDỌ

ETO INU IWE

Ọrọ Asọṣaaju lati Ọdọ Oludari: 03
Ifaara – Alakoso Gbogbo-gboo: 04
Ọrọ Lati Ẹnu Aarẹ: 05
Awọn Agbekalẹ Ati Afojusun Ẹgbẹ Ọdọ Ti Ajọ-Nla Ijọ Onitẹbọmi Naijiria.. 06

ETO ỌSẸ ỌDỌ

1. Eto Isin Ọjọ Isinmi: 07
2. Irọlẹ Ọjọ Isinmi – Idanilẹkọọ nipa Ilera: 08
3. Irọlẹ Ọjọ Aje – Ẹkọ Bibeli: 08
4. Irọlẹ Ọjọ Isegun – Ikọni 09
5. Irọlẹ Ọjọ'ru – Ere Ori Itage/Apejọpọ fun Orin Kikọ: 09
6. Irọlẹ Ọjọ'bo – Akoko Adura: 09
7. Irọlẹ Ọjọ Eti – Ibẹwo si Ibudo Ìfiniwọ̀/ Ọgba Ẹwọn/Ere Orişirişi/ Şişe Afihan Işẹ Ọwọ tabi Işẹ Ọna: 10
8. Owurọ Ọjọ Abameta – Ipejọpọ Ajumọṣe (Ṣiṣe Ayẹyẹ): 11

AWỌN OHUN-ELO FUN ỌSẸ ỌDỌ

1. Itumọ Ori-ọrọ: JADE LỌ (Deutarọnọmi 1:1-13): 12
2. Idanilẹkọọ nipa Ilera: Ìtanijí nipa Aisan Jẹjẹrẹ ati Idena Rẹ: 16
3. Ẹkọ Bibeli: Ẹkọ nipa Igbesi Aye Josẹfu (Jẹnẹsisi 39-40): 23
4. Isin Adura: Agbara ninu Adura (Deutarọnọmi 1:7; Iṣe Awọn Apọsteli 12:5-6; 16:25-26): 27
5. Ere Ori Itage/ Apejọpọ Orin Kikọ: (JADE LỌ) 31
6. Ẹkọ A: Ọrọ Ibaṣepọ (Ibara-ẹni-ṣọrẹ ti O Da le Ete Kan Pato): 35
7. Ibẹwo si Ibudo Ìfiniwọ̀/Ọgba Ẹwọn/Ere Orişirişi/ Ṣiṣe Afihan Iṣẹ Ọwọ tabi Iṣẹ Ọna: 40
8. Ipejọpọ Ajumọṣe: Ṣiṣe Ayẹyẹ: 42
9. Orin Ọsẹ Ọdọ: 46
10. Awọn Onkọwe Fun Ọsẹ Ọdọ............... 47

ỌRỌ ASỌṢAAJU

Pẹlu ọkan ọpẹ, a dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ayẹyẹ ọsẹ ọdọ ọdun miiran. Ọlọrun jẹ olotiitọ si wa ninu awọn Ipade Ọdọ Ajọ-nla Ijọ Onitẹbọmi lati awọn ọdun yii wa. Akoko Ọsẹ Ọdọ Ọlọdọọdun jẹ akoko pataki fun ibẹwo ti ọrun, ati ṣiṣalabapade ninu awọn ijọ wa. Ọlọrun n tẹsiwaju lati maa lo ọsẹ naa lati ran ọpọlọpọ awọn ọdọ lọwọ lati ṣawari ẹbun wọn, ati ki wọn si kopa ninu ọrọ ijọ ati awọn iṣẹ-iranṣẹ ijọ. O jẹ ibi ti a fi n gbe awọn akọni dide fun iṣẹ ami ati iṣẹ iyanu ijọba ọrun ati lati kopa ni gbogbo agbaye lapapọ.

Ọdun pataki ni ọdun yii gẹgẹ bi ọdọ Ijọ Onitẹbọmi, niwọn igba ti a ni ibẹrẹ ọtun: o ti to akoko bayii lati jade lo, ki a já awọn ide nibi Iṣẹ Iranṣẹ awọn Ọdọ Ajọ-nla Ijọ Onitẹbọmi Naijiria, ki a si bọ sinu ibú lati kore lọpọlọpọ. Fun idi eyi, ori-ọrọ fun Ọsẹ Ọdọ ti ọdun yii ni "JADE LỌ!" **(Deutarọnọmi 1:7)**.

Awọn ọkunrin mẹta ni wọn kọkọ gbọ ti Ọlọrun sọrọ. Eyi akọkọ ko ṣe nnkan kan, o sọ pe ohun ti Ọlọrun fẹ ko ye oun. Lẹyin ti ẹnikeji gbọ ohun ti Ọlọrun sọ, o jẹ ki ibẹru bo yoo ṣe ṣe ohun ti Ọlọrun beere bori rẹ. Ẹnikẹta si ran awọn meji akọkọ lọwọ lati le jẹ ki wọn loye iru ẹni ti Ọlọrun jẹ ati bi eniyan ṣe le lọ ba A. O sọ fun wọn bi awọn ṣe le mọ Ọn, ki wọn fẹran Rẹ ati bi wọn ṣe le ni ibaṣepọ pẹlu Rẹ. O kọ wọn bi wọn ṣe le gbe gẹgẹ bi ẹni ti o ni ominira, idalare ati ododo, ki wọn si jẹ ẹni rere. Ni ọdun yii, a n gba Ọlọrun gbọ fun ọna abayọ ni iha gbogbo. Pẹlu Ọlọrun, gbogbo ilẹkun ti o ti ni a o ṣi ni orukọ Jesu. Gbogbo wa ni a o ja awọn idena kuro ni ọna wa, ti a o si jogun ini wa.

Ẹyin ara, bi a ṣe n ṣe ṣe ayẹyẹ Ọsẹ Ọdọ ti ọdun yii, ẹ mura silẹ fun ilẹkun ṣiṣi, iyanu lati ọrun wa, ẹbun ni iha gbogbo, gbigba ohun gbogbo pada, ọna abayọ patapata ati imisi ọtun. Mo ri yin ti ẹ n gbe nnkan nla ṣe, iru eyi ti ẹ ko tii ni iriri iru rẹ ri tẹlẹ. Ọjọ daradara ti de fun yin!

Iwe Eto Ọsẹ Ọdọ ni a ṣe agbekalẹ rẹ ni ọna pataki ki o le nipa ninu aye yin ati ki o le mu yin "Jade Lọ." Ẹ jọwọ ẹ ṣagbátẹrù fun ati pe gbogbo awọn ọdọ yin wa sibi ayẹyẹ ti ọdun yii.

Mo fi ọkan imoore mi han si oṣiṣẹ wa oniwaasu – Ẹni-ọwọ Bunmi Ayodele, mo si tun mọriiri alaga Eto Igbewe-jade wa, gbogbo awọn onkọwe ati olootu wa fun iṣẹ takuntakun ti wọn ti ṣe.

Ẹni-ọwọ Ọmọwe Solomon Ọlawuyi JAMES
Oludari, Iṣẹ-iranṣẹ Awọn Ọdọ ati Awọn Akẹkọọ, Ajọ-nla Ijọ Onitẹbọmi Naijiria
wuyibisi@yahoo.com,
+2348033661505 tabi +2348159990911

Scanned with CamScanner

IFAARA

Ogo ni fun Ọlọrun Olodumare fun oore-ọfẹ lati wa laaye lati ri ayẹyẹ Ọsẹ Ọdọ miiran ninu awọn ijọ wa. Nibi Ipade ọdun kejilelaadọta (52) Awọn Ọdọ ti Ajọ-nla Ijọ Onitẹbọmi Naijiria, Ọlọrun yoo maa ba wa sọrọ nipasẹ ori-ọrọ ti o sọ pe – **"JADE LỌ"** pẹlu ẹsẹ Bibeli ti o wa ninu **Deutarọnọmi 1:7-8.** Ni ọdun yii, Ọlọrun fẹ, O si ṣetan lati mu wa tayọ ibi ti a wa. Ọlọrun yoo maa pe wa lati jade lọ kuro lati inu iriri isọdọtun lọ si ibi ati akoko ilọsiwaju ti ko ni idena. Ẹ mura silẹ lasiko ọsẹ ọdọ ọdun yii lati gba Ẹmi Ọlọrun laaye ti yoo mu yin lọ siwaju ni gbogbo iha aye yin.

A o fi tọkantọkan mọriri rẹ ti gbogbo awọn oniwaasu ijọ wa ba le kopa lẹkunrẹrẹ, ti wọn si gba awọn ọdọ wa niyanju lati ṣe ayẹyẹ ọsẹ Ọdọ ti yoo kun fun iṣalabapade ti ẹmi, ti yoo si jẹ ibukun fun gbogbo awọn ọmọ ijọ. Ọsẹ ọdọ wa fun gbogbo Kristiani, bi o tilẹ jẹ pe awọn ọdọ ni yoo maa dari gbogbo eto ijọ ni ọsẹ yii.

Gbogbo awọn oniwaasu ọdọ, diakoni (lọkunrin ati lobinrin) ati awọn ti n jiṣẹ iranṣẹ kan ni ọna kan tabi omiran fun ọsẹ yii gbọdọ wa oju Ọlọrun, bi O ṣe n lo wọn gege bi ohun-elo lati bukun igbesi aye awọn eniyan ni ọsẹ yii. Ọsẹ Ọdọ saba maa n jẹ ọsẹ ti a maa n ni iṣalabapade ikúnni Ẹmi mimọ ati iriri ayipada ninu igbesi aye awọn eniyan. Ti ọdun yii naa ko ni yẹ kuro ninu iru iriri bayii. A n gbẹkẹle Ọlọrun fun isọji ati ayipada ọkan ti yoo waye ninu gbogbo awọn ijọ lasiko ọsẹ yii.

A gba Ọlọrun gbọ lati jere ọkan fun ijọba Ọlọrun. A tun n gbẹkẹle Ọlọrun pe ni ọsẹ yii, gbogbo ide ifaseyin ati idaduro soju kan yoo já, a o si ni iriri ibukun ati agbara ti ọrun lati jade lo, ki a si gba ogun ini wa.

Mo mọriri gbogbo awọn onkọwe fun Ọsẹ Ọdọ ọdun yii. A gbadura wi pe ki ami oróro Ọlọrun tubọ maa pọ si i ni aye yin! Mo tun mọriri gbogbo awọn oṣiṣẹ Ẹka Iṣẹ-iranṣẹ awọn Ọdọ ati awọn Akẹkọọ fun iṣẹ irubọ wọn ati akitiyan wọn. A gbadura wi pe ki ọwọ Ọlọrun bà le gbogbo yin! A mọriri awọn aladari Ọdọ ni Ajọ-nla fun ipa ti wọn n ko ati ifarajin wọn. Adura mi ni pe ki Ọlọrun bùsi fun gbogbo yin ninu gbogbo awọn iṣẹ-iranṣẹ yin ati idawọle yin ni orukọ Jesu.

Ẹni-ọwọ Collins Ọlatunji
Alakoso Gbogbo-gboo
collinsolatunji96@gmail.com
+2348033220237

ỌRỌ LATI ẸNU AARẸ

Ẹ kaabọ si Ọsẹ Ọdọ 2025! Ẹ kaabọ si akoko ti ohun gbogbo ṣe-e-ṣe!

Inu mi dun lati ki yin kaabọ sibi Ọsẹ Ọdọ 2025. Iyin, ọla ati ogo ni fun orukọ Oluwa ti o mu ki o ṣe e ṣe fun wa lati ri igba miiran lati bọ sinu ipele tuntun ti ikopa laye ẹni ati iṣepataki. Mo mọriri akitiyan ati jijẹ akikanju yin lati rii pe ọsẹ ọdọ ti ọdun yii yọri si rere.

Ayẹyẹ Ọsẹ Ọdọ jẹ ogún ti o ṣe iyebiye ti Ijọ Onitẹbọmi, a si dupẹ lọwọ Ọlọrun pe o jẹ ki a jẹ ara awọn ajogun wọnyi. O fun wa ni anfaani nla lati fi ẹbun ati agbara wa han gẹgẹ bi ọdọ ni gbogbo abala iṣẹ-iranṣẹ ijọ.

Ori-ọrọ wa ni ọdun yii ni **'Jade Lọ!'** pẹlu Bibeli kika lati inu **Deutarọnọmi 1:7**. Ori-ọrọ yii jẹ aṣẹ lati ọrun pẹlu atilẹyin Ọlọrun. O jẹ ikilọ fun wa lati jade lọ, ki a si tẹsiwaju. Eyi duro fun pe ki a dide, ki a tẹsiwaju, ki a si gbe igbesẹ nitori pe eyi ni eto Ọlọrun fun aye wa. Iroyin ayọ ni fun wa ti a ba ṣetan lati tẹle ipe Ọlọrun lati bẹrẹ irin-ajo sinu isọdọtun ati atunṣe patapata kuro ninu iriri buburu ati idena ti atijọ. A ni lati sa ipa wa lati gbagbọ ninu Ọlọrun, ati gbigbe igbesẹ lati wọnu amuṣe ileri Rẹ fun wa lati gba akoso ati lati gba ohun gbogbo ti O ni ni eto fun wa.

Nitori naa, a gbọdọ wọnu igbesi aye tuntun bi Ọlọrun ṣe n ba wa ṣe pẹlu idaniloju lẹkunrẹrẹ pe O jẹ olotiitọ si ileri Rẹ, yoo si mu ohunkohun ti O ba sọ ṣẹ. Pẹlu oye yii, a gbọdọ rii daju pe a fa gbogbo ohun ti n de wa mọlẹ, ti o si n dena awọn ileri lati di mimuṣẹ ni gbogbo isọri igbesi aye wa yọ.

Bi a ṣe n ṣe ayẹyẹ ni ọdun yii, adura mi ni pe ki Oluwa fun wa ni agbara ati oore-ọfẹ ti a nilo lati mu gbogbo awọn akùdé ati idena ti n dena wa lati jade lọ ati lati tẹsiwaju sinu ogo tuntun. Pẹlu Ọlọrun ni iha wa, ohun gbogbo ni ṣiṣe. Inu mi dun lati ki yin kaabọ si akoko ti ohun gbogbo ṣe e ṣe.

Mo ki gbogbo wa ku ayẹyẹ Ọsẹ Ọdọ!

Amb. Tọba Emmanuel Bamidele, ACC. PhD.
Aarẹ Gbogbo-gboo, NBCYC
complex2rime@gmail.com
+234 813 937 9305

Scanned with CamScanner

AWỌN AGBEKALẸ ATI AFOJUSUN ẸGBẸ ỌDỌ TI AJỌ-NLA IJỌ ONITẸBỌMI NAIJIRIA

GBOLOHUN TI A FI ṢE AGBEKALẸ WA

Ajọ Ihinrere awọn Ọdọ Ijọ Onitẹbọmi ni Naijiria (NBCYC) bẹrẹ gẹgẹ bi awujọ awọn onigbagbọ ti wọn n ṣoju Kristi, nipasẹ pipolongo Ihinrere, wiwaasu ihinrere fun gbogbo ẹda, bibikita fun awọn eniyan ati mimu ijọ dagba soke nipasẹ ijọsin, iṣẹ-iranṣẹ, ẹkọ, ilaja ati ifọwọsowọpọ pẹlu awọn ẹgbẹ Kristiani ti ero wọn papọ jakejado agbaye.

AWỌN AFOJUSUN WA

Ijọsin:
A fi ara wa sinu ijọsin fun Ọlọrun nipasẹ Jesu Kristi, Oluwa wa ati Olugbala, gẹgẹ bi a ṣe safihan rẹ nipasẹ awọn ikọni inu Bibeli ti o ṣe pataki, pipolongo Ihinrere fun atunṣe igbesi aye, gbigbadura nigba gbogbo ati ibọwọ-fun ati ijuba fun Ọlọrun.

Idapọ:
Gẹgẹ bi ọdọ Kristiani, apejọpọ wa fun wa ni anfaani lati ni ibaṣepọ ninu idapọ, pẹlu ete ati fun igbagbọ eni kọọkan lokun, ninu ifẹ, ṣiṣe atilẹyin ti o yẹ ati dídá awọn alájùmọ̀-rìnrin àjò pọ̀ lọ si ile ayeraye pẹlu Jesu, Oluwa lọkan le.

Iṣẹ Ihinrere:
Gẹgẹ bi onigbagbọ ninu Aṣẹ Nla Oluwa wa Jesu, a fi ara wa jin si pipolongo Ihinrere nipa mimu awọn alaigbagbọ wa sinu igbagbọ ninu Jesu Kristi ati mimu ihinrere jade lọ si awọn ibi ti wọn ti nilo Ihinrere kiakia ju awọn ibi ti a wa bayii lọ.

Idagbasoke awọn Olori:
Gẹgẹ bi eniyan ti o ni igbagbọ ati iran, a mọ pe a nilo awọn olori ti o yẹ fun Ijọ ati orilẹ-ede. Nitori naa, a farajin si riran ati pipese gbàgede nipasẹ awọn ọdọ Ijọ Onitẹbọmi lati ṣawari, mu itesiwaju ba ati lilo awọn ẹbun ẹmi, pẹlu igboya pe ki wọn le lo wọn gẹgẹ bi olori ti o n dide bọ lati gbe ara Kristi ati awujọ ró.

Idagbasoke tabi Ilọsiwaju pẹlu Iṣẹ Ayanlaayo:
Gẹgẹ bi awujọ awọn ọdọ ti wọn ni itara fun iseso ati ipese, a fi ara jin si riran ara wa lọwọ lati gbe igbesi aye ti o ni ete, nipa pipese gbàgede fun awọn ọmọ ẹgbẹ lati mu ara wọn dagba soke lẹnu iṣẹ ayanlaayo wọn ati ilepa wọn lẹnu ẹkọ de ipele ati le da duro funra wọn ati ti wọn yoo le wulo fun Ijọ ati awujọ lapapọ.

Igbafẹ:
Gẹgẹ bi ọdọ Ijọ Onitẹbọmi pẹlu agbara iṣẹ ọtọọtọ, a fi ara wa silẹ lati ṣafihan itara wa nipa kikopa ninu ere igbafẹ ati ere idaraya, fun ete ati yin Ọlọrun logo ati lati le mu awọn miiran wa sinu imọ Jesu Kristi, pẹlu erongba ati mu ọpọlọpọ wa sinu Ijọ Ọlọrun.

AKỌMỌNA: Maṣe jẹ ki ẹnikẹni ki o gan ewe rẹ (Timotiu Kinni 4:12)

ILANA ETO ỌSẸ ỌDỌ

IJỌSIN OWURỌ ỌJỌ ISINMI
JADE LỌ!
Deutarọnọmi 1:1-13

A PEJỌ PỌ NIWAJU RẸ NIPASẸ:

Kiko Orin Iyin: Awọn Iko Olorin Iyin Ẹgbẹ Ọdọ
Ipe si Isin: Oniwaasu Ijọ
Gbigba Akoso Ipo Adari Ijọ fun Ọsẹ Yii: Oniwaasu Ijọ/Oniwaasu Ọdọ

A KI ARA WA KAABỌ NIPASẸ:

Ọrọ Imọyi: Oniwaasu Ọdọ
Orin Kikọ: Ọba Àìkú, Àìrí, Orisun Ọgbọn: Oludari Orin Ọdọ
Ikini Kaabọ: Akọwe Ọdọ

A GBỌ TI O SỌRỌ NIPASẸ:

Bibeli Kika (Deutarọnọmi 1:1-13): Diakoni Ọdọ (Ọkunrin tabi Obinrin)
Orin Awọn Ẹgbẹ Akọrin: Ẹgbẹ Akọrin Ọdọ tabi ti Ijọ
Iwaasu: Oniwaasu Ọdọ

A DAHUN SI I NIPASẸ:

Kikọ Orin Ifarajin YBH 277 *('Gbat'a B'Oluwa Rin)* Oludari Orin Ọdọ
Ọrẹ ati Idamẹwaa: Diakoni Ọdọ ((Ọkunrin tabi Obinrin)

A TUKA LATI MAA GBE FUN UN NIPASẸ:

Adura ati Oore-ọfẹ: Oniwaasu Ọdọ

Scanned with CamScanner

IRỌLẸ ỌJỌ ISINMI: ỌRỌ ILERA
ITANIJI NIPA AISAN JẸJẸRẸ ATI BI A ṢE LE DENA RẸ

A Bẹrẹ pẹlu Adura Ọpẹ:	Oniwaasu Ọdọ
A gbe Ohùn Wa Soke ninu Kikọ Orin Iyin:	Ikọ Olorin Iyin Ọdọ
Ikini Kaabọ:	Oludari Eto
Fifi Oludari Ere Idaraya tabi Alejo Han:	Oludari Eto
A Tẹle nipasẹ Ere Idaraya:	Alejo Olukọni Elere Idaraya
A kopa ninu Ibeere ati Idahun:	Oludari Eto
Imọyi ati Ifilọ:	Oniwaasu Ọdọ/Akọwe
Dida Owo Ọrẹ:	Diakoni (Ọkunrin tabi Obinrin)
A Pari pẹlu Adura ati Oore-ọfẹ	Oniwaasu Ọdọ

IRỌLẸ ỌJỌ AJE
ETO: ẸKỌ BIBELI
ẸKỌ NIPA AKỌNI KAN: JOSẸFU (Jẹnẹsisi 39-40)

IRỌLẸ ỌJỌ ISEGUN
IKỌNI:

a. **ỌRỌ IBAṢẸPỌ: ṢIṢE ỌRẸ TI O DA LE ETE KAN PATO**
b. **AWỌN KOKO TI O WA FUN ILANA ATI DOKOWO**

A Bẹrẹ Ijọsin pẹlu Adura Ọpẹ:	Aarẹ Ọdọ
A Kọ Orin Adura YBH 277	Oludari Orin Ọdọ
Ikini Kaabọ	Aarẹ Ọdọ
Fifi awọn Alejo Han:	Akọwe Ọdọ
A Feti Silẹ nipasẹ Kika Bibeli:	Diakoni Ọdọ (Ọkunrin tabi Obinrin)
A Gbe Ohùn Wa Soke ninu Orin Iyin:	Ikọ Olorin Iyin awọn Ọdọ
A Gbadura Papọ si Ọlọrun:	Oniwaasu Ọdọ
A Da Owo Ọrẹ wa fun Ọlọrun:	Diakoni Ọdọ (Ọkunrin tabi Obinrin)
A Gbadura, A Si Ṣe Oore-ọfẹ:	Oniwaasu Ọdọ

IRỌLẸ ỌJỌ'RU
ERE ORI ITAGE/ALẸ ORIN KIKỌ (JADE KURO)
ETO IJỌSIN TI A DAMỌRAN

ṢIṢE AYẸYẸ ỌNA ABAYỌ NINU KRISTI NIPASẸ:

Didagba ninu Alaafia:	Ikọ Olorin Iyin/Ẹgbẹ Olorin Iyin awọn Ọdọ
Adura Ọpẹ:	Aarẹ Ọdọ
Kiki Ara Wa Kaabọ ninu Ifẹ:	Oniwaasu Ọsẹ Ọdọ

ṢIṢE AYẸYẸ ỌNA ABAYỌ WA NIPASẸ:

Iṣẹ-iranṣẹ ninu Orin Kikọ	Awọn Ẹgbẹ Akọrin Ọdọ
Iwaasu ninu Ere	Ẹgbẹ Oṣere

ṢIṢE AYẸYẸ ỌNA ABAYỌ BI A ṢE N DAHUN SI I NIPASẸ:

Kikọ Orin: YBH 277 *(Gba T'a B'Oluwa Rin)*	Adari Orin
Dida Ọrẹ Wa:	Ẹgbẹ Akọrin Ọdọ
Adura Pataki:	Oniwaasu Ijọ

ṢIṢE AYẸYẸ ỌNA ABAYỌ BI A ṢE N TUKA NIPASẸ:

Ifilọ Pataki:	Akọwe Ọdọ
Ọrọ Idupẹ:	Aarẹ Ọdọ
Adura Ipari ati Oore-ọfẹ:	Oniwaasu Ọsẹ Ọdọ

AKIYESI:
Alẹ ere ṣiṣe tabi orin kikọ ti Ọsẹ Ọdọ ni a ṣeto lati ko gbogbo ẹgbẹ akọrin papọ ninu awọn ijọ wa lati ṣe ayẹyẹ atunbi wa nipasẹ Jesu Kristi. Ẹ lo ọna atinuda lati ba aini awọn ijọ yin pade. Ẹ ni Ọsẹ Ọdọ alabukun-fun.

ỌSAN TABI IRỌLẸ ỌJỌ'BỌ
AGBARA NINU ADURA

A bẹrẹ Ijọsin pẹlu Adura:	Oniwaasu Ọdọ
A Gbe Ohùn Wa Soke ninu Orin Iyin:	Ikọ Olorin Ọdọ
Ikini Kaabọ:	Oludari Eto
Fifi awọn Alejo Han:	Oludari Eto
A Feti Silẹ si Ọlọrun nipasẹ Bibeli Kika:	Diakoni Ọdọ
A Feti Silẹ si Ọlọrun nipasẹ Iṣẹ-iranṣẹ Alejo Wa	Alejo Oniṣẹ Iranṣẹ
Bibeere Ibeere ati Idahun:	Oludari Eto
A Feti Silẹ si Akiyesi Pataki ati Ifilọ:	Akọwe Ọdọ
A bu Ọla fun Ọlọrun pẹlu Owo Ọrẹ Wa:	Diakoni Ọdọ
A Pari Isin pẹlu Adura ati Oore-ọfẹ:	Oniwaasu Ọdọ

Scanned with CamScanner

IRỌLẸ ỌJỌ ETI

ETO: IBẸWO SI IBUDO ÌFINIWỌ̀/ỌGBA ẸWỌN/ERE ORIṢIRIṢI/ṢIṢE AFIHAN AWỌN IṢẸ ỌWỌ TABI IṢẸ́ ỌNÀ

A Bẹrẹ pẹlu Adura Ọpẹ:	Aarẹ Ọdọ
Ikini Kaabọ ati Idi ti A Ṣe Pejọ:	Oniwaasu Ọdọ
A Ni Idapọ nipasẹ Ṣiṣe Ibẹwo/Afihan Iṣẹ Ọwọ:	Oniwaasu Ọdọ
A Pejọ fun Itaniji ati Ifilọ:	Oniwaasu Ọdọ
A Da Owo Ọrẹ:	Diakoni Ọdọ
A Gbadura si Ọrẹ:	Oniwaasu Ọdọ
A Ṣe Oore-ọfẹ:	Oniwasu Ọdọ

OWURO OJO ABAMETA

IPEJỌPỌ AJUMỌṢE

AKOKO: 10AM

IBI IPADE: IBI TI O BA RỌRUN FUN GBOGBO ENIYAN

OLUDARI: AWỌN OLOYE AJUMỌṢE

AFOJUSUN: ṢIṢE AYẸYẸ

DIDE! TAN IMỌLẸ! (Isaiah 60:1-5; 61:1-4)

Dide ati Fifi Orukọ Silẹ:	Akọwe
A Gbe Ohùn Wa Soke ninu Orin Iyin:	Ikọ Olorin Iyin
Adura Ọpẹ:	Oludari Adura
A Kọ Orin Inu Iwe Orin: Ọba Àìkú, Àìrí, Orisun Ọgbọn	Oludari Orin
Idi ti A Ṣe Pejọpọ ati Fifi Awọn Alejo Han	Igbakeji Aarẹ
Ọrọ Pataki:	Aarẹ
Awọn Ikini: Oludari Awọn Oniwaasu Agbani-nimọran awọn Ọdọ Awọn Oloye Ẹgbẹ Ọdọ	
Iroyin lati Ọdọ awọn Ọdọ ati Ifilọ Pataki:	Akọwe
Adura Pataki fun awọn Oniwaasu Ọsẹ Ọdọ:	Agbani-nimọran/Iya Ẹgbẹ/Baba Ẹgbẹ
Ibeere ti Bibeli:	Alakoso Ibeere
Bibeli Bibeli Kika: Isaiah 60:1-5; 61:1-4	
Orin Awọn Akọrin:	Alejo Iranṣẹ Ọlọrun
Ọrọ Iyanju:	Alejo Iranṣẹ Ọlọrun
A Pari Ọsẹ Yii pẹlu Adura ati Oore-ọfẹ:	
Ase Ifẹ/Ipanu/Ere Idaraya/Ere Oriṣiriṣi:	

Scanned with CamScanner

AWỌN OHUN-ELO FUN ỌSẸ ỌDỌ

ISIN OWURỌ ỌJỌ ISINMI

ILANA IWAASU: ITUMỌ ORI-ỌRỌ

JADE LỌ!

DEUTARỌNỌMI 1:1-13

ỌRỌ IṢAAJU:
A fi gbogbo ogo fun Oluwa fun oore-ọfẹ lati ri Ọsẹ Ọdọ 2025. O tun jẹ akoko idapọ miiran; akoko miiran lati gba aṣẹ lati ọdọ Ọlọrun ati akoko lati fi ara wa fun Oluwa ni igbọran patapata. O tun jẹ akoko jijade lọ miiran lati gba awọn ilẹ fun Oluwa. Ni ọdun ti o lọ, a yẹ ori-ọrọ – 'Isọdọtun' wo. Laiṣiyemeji, mo gbagbọ pe a n ni iriri isọdọtun oore-ọfẹ Rẹ fun iṣẹ-iranṣẹ ti o muna doko laarin awọn ọdọ, laiṣe laarin awọn ọmọ Ijọ Onitẹbọmi nikan, ṣugbọn jakejado agbaye. Gẹgẹ bi awọn ọmọ Israẹli, ti a ko ba ṣora, ti a ko si fura si idari ti Oluwa fi lelẹ fun wa, a o ni itura ni ẹba oke dipo ki a ni iriri ori oke ISỌDỌTUN. Nitori naa, a ko gbọdọ jẹ ki idiwọ kankan wa nitori pe a mọ pe Ilẹ Ileri wa niwaju. A ni lati ni afojusun, ki a si pinnu lati wọ Ilẹ Ileri. Ibeere si wa ni pe gẹgẹ bi ọdọ, njẹ a ti ṣetan lati wọ Ilẹ Ileri ti a ti pese silẹ fun wa? Ti o ba jẹ pe lotitọ a ti ṣetan, ikilọ ti ọrun ti Ọlọrun n ran si wa ni pe 'JADE LỌ.' A ni lati jade lọ kuro ni ibi itura wa; ẹ jade lọ kuro ninu gbogbo ifasẹyin, ẹ jade lọ lati mu ete ati ileri Oluwa ṣẹ.

AWỌN ILANA TI O ṢE PATAKI FUN JIJADE LỌ
Gbogbo eniyan ni n fẹ itẹsiwaju laye. Ko si ẹni ti o fẹ duro si oju kan ni gbogbo abala aye wọn. Lati mu eleyii ṣẹ, awọn ilana wa ti o gbọdọ ye wa, ti a si gbọdọ mu lo ninu igbesi aye wa ojoojumọ. Awọn ilana wọnyi ni:

1. **Ṣiṣe Ayẹwo Ara-ẹni (ẹsẹ 1):** Ẹnikẹni ti yoo ba ni ilọsiwaju nile aye nilo ayẹwo ara-ẹni loorekoore. Eleyii le jẹ ni akoko si akoko, ọjọ de ọjọ tabi oṣu de oṣu. O pe fun bibeere awọn ibeere ti o ṣe pataki ti o fi iru ẹni ti o jẹ han, ibi ti o wa, ohun ti o n ṣe, ibi ti o yẹ ki o wa. Wolii Mose ṣe apejuwe ibi ti awọn ọmọ Israẹli wa lẹyin irin-ajo ogoji ọjọ ninu aginju. Wo ẹyin wo akoko ti o ti fi aye rẹ fun Kristi, kin ni o le sọ nipa idagbasoke rẹ ninu Kristi, irin rẹ, iṣẹ rẹ pẹlu Rẹ, iṣẹ rẹ ninu ara Kristi ati ilọsiwaju ti o ti ni lati mu ete yii ṣẹ? Ṣiṣe ayẹwo ara-ẹni maa n ran eniyan lọwọ lati ni afojusun, laifi aaye gba idiwọ. O maa n ran eniyan lọwọ lati ni ọna abayọ kuro ninu gbogbo idena ati aala (Ẹkun Jeremiah 3:40; Kọrinti Kinni 22:27-28 ati Kọrinti Keji 13:5). O ṣe pataki fun ọ lati mọ pe ogo wa niwaju rẹ. Mura silẹ lati jade kuro, ki o si ni iriri ohun ti Oluwa ni ni ipamọ fun ọ.

2. **Idanimọ Ara-ẹni (ẹsẹ 2):** Ayẹwo ara-ẹni maa n mu idanimọ ara-ẹni wa. Ọpọlọpọ Kristiani lode oni ni o jẹ pe igbesi aye ọ́fútùfẹ̀ẹ̀tẹ̀ ni wọn n gbe. Ọpọlọpọ n gbe igbesi aye itànjẹ, idije ati afiwe. Apọsteli Pọọlu ninu Kọrinti Keji 10:12 sọ pe ki a má ya ara wa sọtọ, tabi ṣe afiwe ara wa pẹlu awọn ti wọn n yin ara wọn, nitori pe nipa ṣiṣe bẹẹ, wọn jẹ alaigbọn. O tun tumọ si pe wọn ko mọ iru ẹni ti wọn jẹ ninu Kristi. Ti o ba mọ iru ẹni ti o jẹ ninu Kristi yoo ran ọ lọwọ lati jade lọ lati gba ogún rẹ ninu Kristi. Nitori naa, bawo ni o ṣe n lo idanimọ rẹ ninu Kristi? Maṣe gbagbe pe ọmọ Ọlọrun ni ọ; a ti pe ọ lati fi ogo Rẹ han. A gba ọ la nipa aye Rẹ lati jẹ imọlẹ laarin okunkun. A pe ọ lati jẹ iyọ ninu aye idibajẹ ati aye ti o ti bajẹ. Njẹ o tun ranti pe alufaa ni ọ, eniyan ọtọ, ti a pe lati fi ẹwa Ọlọrun han ninu aye idibajẹ? Njẹ o ṣetan lati gbe lati fi idanimọ rẹ han ninu Kristi?

3. **Fifi Ọgbọn/Oye Han (ẹsẹ 3-4):** Jesu sọ fun obinrin ti o wa leti kanga pe, "*Wakati naa n bọ, isinsin yii ni, nigba ti awọn olujọsin tootọ yoo sin Baba ni ẹmi ati ni otitọ; nitori pe Baba n wa iru awọn bẹẹ ti yoo sin In. Ẹmi ni Ọlọrun, awọn ti n sin In ko le ṣalai sin In ni ẹmi ati otitọ,*" (Johanu 4:23-24). Eniyan ti o ba ṣetan lati jade lọ ni ẹni ti n gbe ni ojoojumọ ni ibamu pẹlu idari Ẹmi Mimọ. Ẹni ti o ba n gbe ninu ara yoo dojukọ idiwọ ninu ọrọ ile aye. Apọsteli Pọọlu ninu Roomu 8:13-15 gba wa niyanju pe ẹnikẹni ti o ba n gbe ninu ara yoo ku; ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba n gbe ninu Ẹmi Ọlọrun ni ọmọ Ọlọrun. Njẹ lotitọ ni o jẹ ọmọ Ọlọrun, njẹ Ẹmi Mimọ n dari rẹ lojoojumọ? Ni ifura si igbesẹ Ọlọrun, o ko si ni bọ si oko-ẹru eṣu.

4. **Igbọran (Ẹsẹ 5-8):** Ẹni ti o ba kun fun ẹmi Ọlọrun ni ẹni ti a pe sinu igbesi aye igbọran. Ọkan ninu ilana ti o ṣe pataki lati jade lọ lati maa gbe igbesi aye ẹkunrẹrẹ ni igbesi aye igbọran si Ọrọ Oluwa. Igbọran ni oore-ọfẹ lati maa gba ikilọ ti Ọlọrun lojoojumọ. Ọpọlọpọ awọn ayanmọ ni o ti bajẹ nitori aigbọran. Ọba Sọọlu padanu itẹ ati ibaṣepọ rẹ pẹlu Ọlọrun, Samsoni padanu ifami-ororo-yan ati ibaṣepọ rẹ pẹlu Ọlọrun ati pe Wolii lati Juda padanu ipe ati igbesi aye rẹ nipasẹ aigbọran. Awọn ibukun Ọlọrun wa ninu igbọran si Ọlọrun. Apọsteli Pọọlu ninu Iṣe Awọn Apọsteli 26:19-20 fi aṣiri aṣeyọri iṣẹ-iranṣẹ rẹ han. O wi fun Ọba Agrippa pe, "Nitori naa, Agrippa ọba, emi ko ṣe aigbọran si iran ọrun naa. Ṣugbọn mo kọ sọ fun awọn ti o wa ni Damasku, ati ni Jerusalẹmu, ati ja gbogbo ilẹ Judea. Ati fun awọn Keferi, ki wọn o ronupiwada, ki wọn si yipada si Ọlọrun, ki wọn maa ṣe iṣẹ ti o yẹ si ironupiwada." Ni igba wo kẹyin ni o gbọran si ikilọ ti Oluwa fun ọ? Ti o ba fẹ jade lo kuro, o gbọdọ gbe igbe-aye igbọran. Wolii Isaiah wi pe, "Bi ẹyin ba fẹ, ti ẹ si gbọran, ẹyin o jẹ ire ilẹ naa" (Isaiah 1:19). Ilẹ kun fun

Scanned with CamScanner

ọpọlọpọ awọn ibukun Oluwa ti o n duro, eyi ti o le gba nipasẹ igbọran aye rẹ. Ma ṣalai kopa nibẹ.

5. **Gbigbẹkẹle Ọlọrun (ẹsẹ 9-12):** Iriri Hannah gẹgẹ bi a ṣe ṣapejuwe rẹ ninu Samueli Kinni 2:9 jẹ ki o han gbangba pe ẹnikẹni ti yoo ba jade kuro, ti yoo si gba ilẹ naa gbọdọ gbarale Ọlọrun patapata. Hannah sọ pe Ọlọrun yoo pa ẹsẹ awọn eni mimọ Rẹ mọ, awọn eniyan buburu ni yoo dakẹ ni okunkun. Nipa agbara ko si ọkunrin ti yoo bori. Eleyii jẹ ikadii ti o dara pe agbara eniyan tabi ọgbọn ko le bori. Njẹ o fẹ iṣẹgun ninu aye rẹ? A jẹ pe ki o kọ lati maa gbe igbesi aye ti o gbarale Oluwa. Ẹ maṣe dabi aṣiwere ti o kọ Ọlọrun silẹ, ti o wa wi pe, "Ahọn wa ni awa o fi ṣẹgun; ete wa ni ti wa; ta ni i ṣe oluwa wa?" (Orin Dafidi 12:4). Jẹ ọlọgbọn, tẹle ọrọ Oluwa ninu iwe Owe 3:5-8 ti o wi pe, "Fi gbogbo aya rẹ gbẹkẹle Oluwa, ma si ṣe tẹ si imọ ara rẹ. Mọ on ni gbogbo ọna rẹ: oun o si maa tọ ipa-ọna rẹ. Maṣe jẹ ọlọgbọn ni oju ara rẹ; beru Oluwa, ki o si kuro ninu ibi. Oun o si ṣe ilera si idodo rẹ, ati itura si egungun rẹ." Njẹ o ṣetan lati jade lo! Ti o ba ri bẹẹ, wọnu ileri ogo, ayọ alailẹfẹnusọ ati amuṣẹ nipa gbigbẹkẹle Oluwa patapata ninu ohun gbogbo.

6. **Ibaṣepọ Olori ati Ọmọlẹyin (ẹsẹ 13):** Ni akoko kan, o yẹ ki Mose yan awọn olori, awọn eniyan si gbọdọ ṣetan lati tẹle e. Nitori naa, wiwọnu Ilẹ Ileri pe fun ibaṣepọ olori ati ọmọlẹyin; wọn nilo ibaṣepọ ti o muna doko laarin awọn olori ati awọn ọmọlẹyin. Nigba ti Ọlọrun fẹ mu awọn ọmọ Israẹli kuro ni ilẹ Egipti, O pe Mose. O yan Gideoni lati tu awọn eniyan Rẹ silẹ kuro lọwọ awọn ara Filistini. Ta ni olori rẹ, bawo si ni o ṣe n tẹle e tabi jẹ eni ti o n gbọran si ikilọ ti ọrun si? Ti o ba jade kuro, ti o si ni iriri ifarahan Ọlọrun, o ni lati mu idagbasoke ba ibaṣepọ rẹ pẹlu awọn olori ti Ọlọrun yan fun ọ. Jesu ninu Matiu 9:36 fi aworan eniyan ti ko ni oluṣọ-agutan han wa. Iwe Mimọ wi pe, "Ṣugbọn nigba ti o ri ọpọ eniyan, aanu wọn ṣe e, nitori ti aarẹ mu wọn, wọn si tuka kiri bi awọn agutan ti ko ni oluṣọ." Eniyan ti ko ni oluṣọ padanu idari. O jẹ ẹni ti ko ni ete ati ibi ti o n lọ. Iru awọn eniyan bawọnyi n gbe ninu idaamu, wọn si jẹ iṣoro si gbogbo nnkan. Njẹ o jẹ ọmọlẹyin ati olori tabi adari olotiitọ?

ỌRỌ IPARI:

Ọlọrun ti ko ilẹ yii le ọ lọwọ (ọrọ igbeyawo, ọrọ owo, oko-owo, ilera, awọn ọmọ ati igbega), jade ki o si gba akoso. Ninu iwe Deutarọnọmi, Oluwa sọ pe, "Wo o, mo ti fi ilẹ naa siwaju yin, ẹ wọ ọ lọ ki ẹ si gba ilẹ naa ti OLUWA bura fun awọn baba yin" (Deutarọnọmi 1:6-8). Awọn nnkan wo ni o n dena rẹ? Duro lonii lori ododo Kristi, ki o si jade kuro gẹgẹ bi Dafidi lati bori Goliati rẹ. Dide ninu igbagbọ gẹgẹ bi

Hannah lati gba awọn ọmọ rẹ. Eyin arakunrin ati arabinrin, ẹ dide lori ẹsẹ yin gẹgẹ bi Josefu lati jokoo lori ite gẹgẹ bi oba lori gbogbo awọn ipenija yin. Eyin ara, ẹ dide tan imọlẹ, nitori imọlẹ yin ti de, ogo Oluwa si yọ lara yin. Nitori kiyesi i, okunkun bo aye mọlẹ, ati okunkun biribiri bo awọn eniyan, ṣugbọn Oluwa yoo yọ lara rẹ, a o si ri ogo Rẹ lara rẹ. Ohun ti o jẹ iroyin ayọ ni pe, awọn Keferi yoo wa si imọlẹ, ati awọn ọba si titan yiyọ rẹ. Ṣe iwọ yoo ja Oluwa kulẹ? Ṣe ipinnu lonii lati duro fun Oluwa bi o ṣe n jade kuro lati tan imọlẹ ihinrere Kristi.

Scanned with CamScanner

ISIN IRỌLẸ ỌJỌ ISINMI

ETO: ỌRỌ ILERA

JẸJẸRẸ: ÌTANIJÍ ATI ÌDÈNÀ

Ọrọ Iṣaaju

Jẹjẹrẹ ti di ọrọ ilera ti ko mu ki ọkan awọn eniyan balẹ jadejado gbogbo agbaye, ti a ba wo bi awọn eniyan ṣe n ku pupọ nipasẹ rẹ ati bi awọn eniyan ṣe n di aláàbọ̀ ara (Huang, Sentogo ati Sharma, 2023). Aisan jẹjẹrẹ ni o jẹ arun ti o leke julọ ti n ṣokunfa iku jakejado agbaye, oun ni o ṣokunfa eniyan bii miliọnu mẹwaa ni ọdun 2020, tabi ti o jẹ pe ẹnikan ninu eniyan mẹfa ti o ba ku ni o ku nipasẹ arun jẹjẹrẹ (WHO, 2022). Ni 2020, aisan jẹjẹrẹ tuntun bii 18.1 million ni wọn tun ri kaakiri agbaye (World Cancer Research Fund International, 2022). Aisan jẹjẹrẹ jẹ oriṣi arun kan ti o maa n mu ki awọn ẹran ara ati iho ara dagba soke lailodiwọn, ti o si n ràn kaakiri gbogbo ara. Bi aisan yii ṣe n dagbasoke rọ mọ ajogunba, agbegbe, iru igbesi aye ti a n gbe (Shaukat, Ismail and Mehmood, 2013; Baroudi and Benammar-Elgaaied, 2016).

Nigba ti awọn iho ara ba ti gbó tabi ti wọn ba ti bajẹ, wọn a ku, awọn ẹran ara miiran yoo si rọpo wọn. Ṣugbọn sa, ilana yii le yipada, nitori naa, yoo wa fi aaye gba ẹran ara ti ko dá pé tabi eyi ti o ti bajẹ lati dagba, ki o si maa pọ sii nigba ti ko yẹ ki wọn ṣe bẹẹ. Awọn ẹran ara wọnyi le di ara wíwú nibomiran ti a tun mọ si *neoplasms,* eyi ti i ṣe kókó keekeeke ninu ara tabi kókó ti o ni omi ninu (Tarini, 2018).

Awọn ara ti o wú wọnyi le jẹ eyi ti o le yọri si jẹjẹrẹ tabi eyi ti ko le yọri si aisan jẹjẹrẹ (Patel, 2020). Awọn kókó ninu ara wọnyi ti ko le di jẹjẹrẹ ni awọn ti o wa ni ibi ti Ọlọrun da wọn si, wọn kii ran de abala ara miiran (Patel, 2020). Wọn kii ran lọ sibi awọn ẹya miiran tabi ibi kọ́lọ́fín ninu ara. Awọn kókó ti ko le di jẹjẹrẹ ninu ara wọnyi maa n dagba diẹdiẹ, wọn si ni ibi ààlà wọn. Wọn kii saba fun eniyan ni iṣoro, bẹẹni wọn kii saba sọ jade mọ lẹyin ti eniyan ba ti yọ wọn danu. Ṣugbọn sa, wọn tun le dagba soke pada, ki wọn si maa tẹ abala ara ti o wa lẹgbẹ wọn, eyi le mu irora tabi ọrọ ilera miiran wa. Ṣugbọn awọn kókó inu ara ti o le di jẹjẹrẹ ni tirẹ ni a mọ si aisan jẹjẹrẹ. Wọn maa n ran tabi gba gbogbo awọn agbegbe ti o ba sunmọ ibi ti wọn wa, wọn si le ran de ibi ti o jinna ninu ara lati tun ṣe kókó tuntun miiran sibẹ, eleyii ni a mọ si *metastasis* ni ede oyinbo (Patel, 2020). Wọn maa n tan lọ si ibi ti o jinna lati inu ẹjẹ ara tabi omi ara (*lymphatic system*).

ORIṢIRIṢI JẸJẸRẸ TI O WA

Nigba ti o jẹ pe oriṣiriṣi aisan jẹjẹrẹ ti o wa le ni ọgọrun kan, awọn kan wọpọ ju awọn miiran lọ.

1. Jẹjẹrẹ ọyan/ọmu
2. Jẹjẹrẹ ọna ọfun

3. Jẹjẹrẹ ẹnu ile iyagbẹ
4. Jẹjẹrẹ nibi abẹ ọmọkunrin (ẹpọn)
5. Jẹjẹrẹ awọ ara
6. Jẹjẹrẹ ẹnu ile ọmọ
7. Jẹjẹrẹ ẹnu ile ẹyin ọmọ
8. Jẹjẹrẹ àmọ́
9. Jẹjẹrẹ inu ikun
10. Jẹjẹrẹ kíndìnrín
11. Jẹjẹrẹ ẹ̀dọ̀

Oriṣi kọọkan ni o ni abuda ti o da wọn yatọ, wọn ni ewu ti wọn mu dani, wọn si ni ilana bi a ṣe le yẹ wọn wo.

AWỌN AMI ATI APẸRẸ AISAN JẸJẸRẸ

Awọn ami ati aisan jẹjẹrẹ yatọ si ara wọn, o da le iru eyi ti o ba jẹ, ibi ti o wa ati ipo ti aisan naa ti de. Lara awọn ohun ti o wọpọ ti o saba maa n farahan ni ki eniyan maa rù, ki o maa rẹ ara loorekoore, bi eniyan ṣe n ṣe ìgbọ̀nsẹ̀ tabi tọ̀ yoo yipada, ẹ̀jẹ̀ a maa dà jade ni ara tabi omi ara miiran a maa sun jade, eniyan a maa húkọ́ fun igba pipẹ, yoo ṣoro lati gbe nnkan mì, awọn kókó kókó yoo maa jade ni ara (American Cancer Society, 2021a). Lara awọn ami miiran ni ki ayipada ba ọmú (ki kókó wa ninu ọmú, ki o maa yọ omi jade tabi ki ori ọmú yipada, ki ara maa yún eniyan tabi ki ara maa jìn sinu), bi eniyan ṣe n tọ́ yoo yipada (iṣoro yoo wa lati tọ̀, irora a wa ti eniyan ba n tọ̀ tabi ki ẹ̀jẹ̀ ba ìtọ̀ jade), bi eniyan ṣe n ṣe ìgbọ̀nsẹ̀ yoo yipada, iṣoro yoo wa lati jẹun, eniyan a ni aisan ibà, awọn omi ara yoo yipada, bẹẹni iwọn ara naa yoo yipada (National Cancer Institute, 2021a). O ṣe pataki lati mọ pe awọn ami wọnyi naa le waye pẹlu awọn aisan miiran ti kii ṣe jẹjẹrẹ; ṣugbọn sa, ti awọn ami naa ba kọ̀ ti ko lọ, tabi ti o n buru si i, o pe fun ki eniyan wa iranlọwọ ilera lati ṣe ayẹwo rẹ lati mọ boya jẹjẹrẹ ni tabi nnkan miiran.

AWỌN EWU TI O RỌ MỌ AISAN JẸJẸRẸ

Lara awọn ewu ti o rọ mọ aisan jẹjẹrẹ ni pe o jẹ àjogúnbá, o maa n wa ni agbegbe, ati pe o le waye nipasẹ iru igbesi aye ti a n gbe ti o fi aaye gba ati dagba aisan naa ninu ara (Baroudi and Benammar-Elgaaied, 2016). Ayipada ti n waye nipasẹ àjogúnbá le mu ewu wa lati ni arun ti o le yọri si jẹjẹrẹ. Gẹgẹ bi apẹrẹ BRCA1 ATI BRCA 2 jẹ awọn omi ara ti o rọ mọ jẹjẹrẹ ọyàn ati ti ẹnu ile ẹyin (Angeli, Salvi ati Tedaldi, 2020).

Awọn koko ti o rọ mọ agbegbe bii siga mimu, *asbestos* ti a fi n ṣe àjà ile ati ìtànṣán oorun (Ultraviolet) [UV]) ni gbogbo wọn ni ipa pataki. Gẹgẹ bi o ṣe wa ni akọsilẹ ninu ẹkọ laipẹ yii, ida 80% si 90% awọn kókó ti o n maa n di jẹjẹrẹ n waye nipasẹ

Scanned with CamScanner

awọn koko ti o rọ mọ agbegbe wa paapaa eyi ti a mọ si oogun olóró [*carcinogens*] (Lewandoska, Rudzki, Rudzki, Lewandowski ati Laskowska, 2018).

Iru igbesi aye ti a yan lati gbe naa bii mimu siga tabi mimu ọti lile, aijẹun ti o dara, aiṣe ere idaraya ti o yẹ ninu ara, ati diduro si abẹ oorun ti o mu ju nigba gbogbo, jẹ awọn koko ti o ṣe pataki ti a le mojuto nipa ṣiṣe ayipada ninu iṣe wa (McCormack ati Boffetta, 2011). Bii ida ogun (20%) gbogbo aisan jẹjẹrẹ ni a le so mọ sísanra jù (De Pergola ati Silvestris, 2013).

Ṣiwaju sii, awọn arun ti o maa n ran bii *papillomavirus* (HPV) ni o so mọ jẹjẹrẹ ẹnu ile ọmọ ati awọn arun ti n di jẹjẹrẹ miiran ninu ara eniyan, nigba ti arun ẹ̀dọ̀ wíwú hepatitis B ati C so mọ jẹjẹrẹ nibi ẹ̀dọ̀ ti a mọ si *hepatocellular* (Schiller ati Lowry, 2021).

BI A ṢE LE TETE MỌ NIPA ARUN YII ATI AWỌN OHUN TI A FI N MỌ PE JẸJẸRẸ NI

O ṣe pataki lati tete mọ arun yii ati lati mọ pe jẹjẹrẹ ni ki itọju le wa fun ẹni ti o ni arun naa ati ki o le din iku ti o rọ̀ mọ arun naa ku (Crosby, Bhatia, Brindle, Coussens, Dive, Emberton, Esener, Fritzgerald, Gambhir, Kuhn, Rebbeck ati Balasubramanian, 2022). Titete mọ igba ti o ba ṣẹṣẹ bẹrẹ maa n fi aaye gba ati tete mojuto o, ati itọju ni ibẹrẹ pẹpẹ, eyi ti o le yọri si ki iṣesi ti o san waye nipasẹ itọju naa, tabi ki o mu itẹsiwaju ba ara ẹni naa (Wardle, Robb, Vernon ati Waller, 2015).

Eto ayẹwo wa fun ati tete mọ boya jẹjẹrẹ naa ko tii dagba pupọ ninu ara, eyi si ti fi anfaani pataki han nipa ṣiṣe àdínkù bi awọn eniyan ṣe n ku, ati mimu ilọsiwaju ba asọtẹlẹ ọjọ iwaju nipa rẹ. Awọn eto wọnyi n lo ayẹwo orisirisi bii eyi ti a mọ si yiya aworan mammography, colonoscopy, pap smears, ati prostate-specific antigen (PSA), lati mọ boya jẹjẹrẹ naa ṣẹṣẹ n bẹrẹ ninu ara ni nigba ti o ṣi le gbọ itọju daadaa (Carrasco-Garrido, Hernandez-Barrera, Klopez de Andres, Jimenez-Trujillo, Galllardo Pino ati Jimenez-Garcia, 2014; Sung, Luk, Ng, Chiu, Chan, Cheung, Chu, Wong, Lam ati Wong, 2021). Lara ilana ti wọn n gba ṣe ayẹwo arun jẹjẹrẹ ọyàn fun obinrin ni digital mammography, digital breast tomosynthesis, yiya aworan ọyan [breast ultrasonography], magnetic resonance imaging, ati ayẹwo nile ayẹwo [clinical breast examination] [Florida, 2016]. Awọn ayẹwo wọnyi ni wọn damọran ti a ba wo awọn koko bii ọjọ ori, iru ẹni ti a jẹ, ọkunrin tabi obinrin, ati itan idile.

Ni afikun, ilọsiwaju ti o waye nipa lilo awọn aworan imọ ẹrọ, biomarker discovery ati ṣiṣe ayẹwo nipa àjogúnbá, ti ran imunadoko ati da arun jẹjẹrẹ mọ lọwọ.

AWỌN IPELE ARUN JẸJẸRẸ

Bi arun jẹjẹrẹ ṣe n gbooro ni a pin si ipele ipele nipasẹ bi awọn koko naa ṣe n dagba ni ara, bi o ṣe n ran de ibi awọn ẹran ara, ati bi o ṣe n yipada nipa bi o ṣe n jinna si. Awọn ipele wọnyi fun wa ni iroyin ti o ṣe iyebiye fun eto itọju ati ayẹwo ọjọ iwaju.

Awọn ipele wọnyi ni wọn maa n ṣapejuwe rẹ pẹlu onka Roomu, pẹlu Ipele 0 ti o duro dun jẹjẹrẹ *in situ*, eyi ni jẹjẹrẹ ti o wa ninu ibi ti o ti bẹrẹ, ati Ipele IV ti o duro fun aisan naa ti o ti gbooro i.e. jẹjẹrẹ ti o ti tan kaakiri. Awọn ipele wọnyi fi orisirisi awọn koko kan han bii bi kókó naa ṣe tobi to, boya ẹran ara naa yọ sita, boya o ràn kiri ti o si n ba awọn ibi ti o ran de jẹ, eyi gba awọn oniṣẹ iṣegun laaye lati pin jẹjẹrẹ naa si aaye ti o yẹ bii ibi ti o ti bẹrẹ, agbegbe tabi ipele ti o jin rere.

Ọna kan ti o wọpọ ti a fi n pin jẹjẹ si ipele bii ilana TNM, ṣapejuwe bi jẹjẹrẹ se n dagba lara ẹni ti o ni in nipa lilo *phenotypic variable,* T lati duro fun bi kókó naa ṣe to, N, eyi ni bi awọn koko naa ṣe tan kalẹ si, ati M, ti o n sọ bi jẹjẹrẹ ṣe ba ibi ti o tan de jẹ si (Chen, 2012).

Gẹgẹ bi apẹrẹ, bi jẹjẹrẹ ba ṣẹṣẹ bẹrẹ a le pin in si ipele marun-un ti i ṣe T0, T1, T2, T3 ati T4. A pin awọn ipele yii lọna ati fi han pe ipele ti o kere ju duro fun arun jẹjẹrẹ naa ti idagba soke rẹ kere, ati awọn ẹran ati isan ti o wa lẹgbẹ rẹ (Chen, 2012).

Tito arun jẹjẹrẹ si ipele ni o ṣe pataki julọ lati mọ iru itọju ti a nilo, ati bi a ṣe le mọ boya ẹni ti o ni arun yii yoo yè tabi bẹẹkọ. Bi ipele ti arun jẹjẹrẹ wa ba ye wa, yoo ran wa lọwọ lati ṣe ipinnu nipa gbigba iwosan, niwọn igba ti wọn maa n ṣe iṣe abẹ fun arun jẹjẹrẹ ti o ṣẹṣẹ bẹrẹ tabi ki wọn lo iwosan gbigbe ẹni naa si abẹ itàsán iná, ṣugbọn ti o ba jẹ ipele ti o ti gbooro ni, o le pe fun gbigba itọju bii *Chemotheraphy, targeted therapy,* tabi *immunotherapy* (American Cancer Society, 2021b; National Cancer Institute, 2021b).

DIDENA ARUN JẸJẸRẸ

Lara koko pataki lati dena arun yii ni dida mimu tábà duro, nitori pe siga mimu le ṣokunfa ki orisirisi jẹjẹrẹ dide, pẹlu jẹjẹrẹ ọna ọ̀fun, ti ibi ọrùn, ti ẹnu ile itọ̀ (Suresh Pichandi, Palanisamy Pasupathi, Yagneswara Rao, Jawar Farook, Babu Shankar Ponnusha, Athimoolam Ambika, Sathiyamoorthy Subramaniyam, 2011). Ni afikun, ki eniyan jẹ ki ìwọ̀n oun duro si ibi ti o ti fun un ni ilera pipe, jijẹ ounjẹ ti o ṣara loore ati ṣiṣe ere idaraya loorekoore le din ewu ati sanra àsanjù ku bii jẹjẹrẹ ọyàn, ti ẹnu ile iyagbẹ ati ti inu ile ọmọ (Colditz ati Patterson, 2018). Dindin mimu ọti lile ku ati lilo itasan oorun UV naa le ran akitiyan ati dena arun jẹjẹrẹ lọwọ (Cao ati Giovannucci, 2016; Lewandowska et al., 2018).

Scanned with CamScanner

Gbigba abẹ́rẹ́ lati dena awọn ohun ti n fa arun jẹjẹrẹ bii *human papillomavirus* (HPV) ati *hepatitis* B Virus (HBV), jẹ ọna ti o muna doko miiran ti o n dena jẹjẹrẹ yii (Schiller ati Lowry, 2021).

Ṣiṣe ayẹwo arun jẹjẹrẹ loorekoore lati le mọ boya eniyan ni in tabi bẹẹkọ jẹ ipa ti o ṣe pataki lati le mọ iru igbesẹ ti eniyan le gbe nigba ti itọju ti a n gba ko ba to. Ṣiṣe ayẹwo lookoore le jẹ ki eniyan tete mọ boya eniyan ni jẹjẹrẹ ọyàn, ti ẹnu ile ọmọ, ti ẹnu ile iyagbẹ ati awọn iru arun jẹjẹrẹ miiran (Gorina ati Elgaddal, 2021).

ITỌJU ARUN JẸJẸRẸ

Orisirisi itọju ni o wa fun arun jẹjẹrẹ. Lara eleyii ni (National Cancer Institute, 2023):

a. Chemotherapy: Chemoterapy jẹ oriṣi itọju arun jẹjẹrẹ kan ti wọn n lo oogun lati pa awọn jẹjẹrẹ wọnyi ninu ara.

b. Hormone therapy: Homone therapy jẹ oriṣi itọju kan ti o n dín tabi dá idagbasoke jẹjẹrẹ ninu ọmú ati àpò nnkan ọmọkunrin ti n lo omi ara lati dagba kù.

d. Hyperthermia: Hyperthermia jẹ oriṣi itọju kan nibi ti wọn ti mu ẹran ara gbona de bii 113°F lati ṣe iranwọ lati ba awọn jẹjẹrẹ naa jẹ ati lati pa a patapata, eyi ti o le mu inira tabi ewu kekere lọwọ, tabi ki o ma si inira kankan lati da a pada si ipo ti o yẹ.

e. Immunotherapy: Immunotheraphy jẹ oriṣi itọju arun jẹjẹrẹ kan ti o n ran àjẹsára ara eniyan lọwọ lati ba arun jẹjẹrẹ ja.

ẹ. Photodynamic therapy: Photodynamic therapy jẹ itọju eyi ti n lo oogun ti a fi iná sọjí lati pa jẹjẹrẹ ati awọn ẹran miiran ti o ti n dagba soke.

f. Radiation: Radiation therapy jẹ oriṣi itọju arun jẹjẹrẹ ti n lo ìtàsán iná ti o pọ lati pa jẹjẹrẹ ati lati yọ́ awọn koko ti n dide ninu ara.

g. Stem Cell Transplants: Awọn wọnyi ni ilana ti a fi n da awọn eroja ti o dide ninu ẹ̀jẹ̀ pada sipo ninu ara eniyan ti tirẹ ti bajẹ nitori itọju chemotherapy ati radiation ti o n la koja.

gb. Iṣẹ Abẹ: Nigba ti wọn ba lo o lati wo arun jẹjẹrẹ san, iṣẹ abẹ jẹ ilana ti awọn oniṣegun oyinbo n lo lati mu arun jẹjẹrẹ kuro ninu ara eniyan.

i. Targeted therapy: Targeted therapy jẹ oriṣi itọju arun jẹjẹrẹ ti o fojusun ayipada ninu omi ara ti n ran wọn lọwọ lati dagba, lati pin ati lati tan kaakiri.

Iru itọju ti alaisan yoo gba da le iru arun jẹjẹrẹ ti o ba ni ati bi o ṣe gbooro to ninu ara iru ẹni bẹẹ. Awọn ẹlomiran ti wọn ni arun jẹjẹrẹ yoo gba itọju ẹyọ kan ṣoṣo, nigba ti ọpọlọpọ awọn eniyan yoo gba oriṣiriṣi awọn itọju lapapọ, bii iṣẹ abẹ pẹlu chemotherapy ati radiation therapy.

ỌRỌ IPARI

Bi o tilẹ jẹ pe jẹjẹrẹ jẹ arun ti o le ṣekú pani, gbigbe igbesẹ loju ẹsẹ ni ki a maa ta awọn eniyan jí, ati pe ki a lo awọn igbesẹ ti o le dena rẹ ṣe pataki gidigidi lati din ipa rẹ kù lara awọn eniyan ati ninu awujọ lapapọ. Nipa ṣiṣe agbega fun awọn koko ti o lewu, ṣiṣe agbega fun gbigbe igbesi aye ti o lalaafia, ati ṣiṣe atótónu fun ati tete mọ boya eniyan ni arun yii tabi bẹẹkọ nipa ṣiṣe ayẹwo, gbogbo wa le bori arun jẹjẹrẹ. Gbogbo eniyan, paapaa awọn eniyan ti wọn wa ninu ewu ati ni arun jẹjẹjẹ gbọdọ rii daju pe wọn n gbe igbesi aye ilera pipe, ki wọn si maa lọ fun ayẹwo arun jẹjẹrẹ loorekoore.

Awọn Iwe Itọkasi

- American Cancer Society. (2021a). Signs and symptoms of cancer. https://www.cancer.org/cancer/cancer-basics/signs-and-symptoms-of-cancer.html
- American Cancer Society. (2021b). Cancer stages. https://www.cancer.org/cancer/cancer-basics/staging.html
- Angeli D, Salvi S, Tedaldi G (2020). Genetic Predisposition to Breast and Ovarian Cancers: How Many and Which Genes to Test? Int. J. Mol. Sci; 21(3): 1128
- Baroudi O, Benammar-Elgaaied A (2016). Involvement of genetic factors and lifestyle on the occurrence of colorectal and gastric cancer. Critical Reviews in Oncology/Hematology, 107: 72-81
- Cao Y, Giovannucci EL (2016). Alcohol as a Risk Factor for Cancer. Seminars in Oncology Nursing; 32(3): 325-331
- Carrasco-Garrido P, Hernandez-Barrera V, Lopez de Andres A, Jimenez-Trujillo I, Gallardo Pino C, Jimenez-Garcıa R (2014). Awareness and uptake of colorectal, breast, cervical and prostate cancer screening tests in Spain, European Journal of Public Health; 24,(2):264–270
- Chen CK (2012). The classification of cancer stage microarray data, Computer Methods and Programs in Biomedicine; 108(3): 1070-1077
- Colditz GA, Peterson LL (2018). Obesity and Cancer: Evidence, Impact, and Future Directions. Clinical Chemistry; 64(1): 154–162
- Crosby D, Bhatia S, Brindle KM, Coussens LM, Dive C, Emberton M, Esener S, Fitzgerald RC, Gambhir SS, Kuhn P, Rebbeck TR, Balasubramanian S. (2022). Early detection of cancer. Science 375 (6586): eaay9040
- De Pergola G, Silvestris F. (2013). Obesity as a Major Risk Factor for Cancer. Journal of Obesity, vol. 2013, Article ID 291546
- Florica JV (2016). Breast Cancer Screening, Mammography, and Other Modalities. Clinical Obstetrics and Gynecology 59(4): 688-709
- Gorina Y, Elgaddal N (2021). Patterns of Mammography, Pap Smear, and Colorectal Cancer Screening Services Among Women Aged 45 and Over. National health statistics reports, (157), 1–18.
- Huang J, Ssentongo P, Sharma R. Editorial: Cancer burden, prevention and treatment in developing countries. Frontiers in Public Health. 2023 Feb 7; 10:1124473. doi: 10.3389/fpubh.2022.1124473. PMID: 36845348; PMCID: PMC9945280.

Scanned with CamScanner

- Lewandowska AM, Rudzki M, Rudzki S, Lewandowski T, Laskowska B (2018). Environmental risk factors for cancer-review paper. Annals of Agricultural and Environmental Medicine; 26 (1): 1-7
- McCormack VA, Boffetta P (2011). Today's lifestyles, tomorrow's cancers: trends in lifestyle risk factors for cancer in low- and middle-income countries. Annals of Oncology; 22(11): 2349-2357
- National Cancer Institute (2023). Cancer treatment. https://www.cancer.gov/about-cancer/treatment#:~:text=Some%20people%20with%20cancer%20will,be%20an%20option%20for%20you. (assessed March 24, 2024)
- National Cancer Institute. (2021a). Symptoms of cancer. https://www.cancer.gov/about-cancer/diagnosis-staging/symptoms
- National Cancer Institute. (2021b). Cancer staging. https://www.cancer.gov/about-cancer/diagnosis-staging/staging
- Patel A (2020). Benign vs Malignant Tumors. JAMA Oncol. 2020;6(9):1488.
- Schiller JT, Lowy DR (2021). An Introduction to Virus Infections and Human Cancer. In: Wu TC, Chang MH, Jeang KT (eds). Viruses and Human Cancer. Recent Results in Cancer Research, vol 217. Springer, Cham.
- Shaukat U, Ismail M, Mehmood N (2013). Epidemiology, Major Risk Factors and Genetic Predisposition for Breast Cancer in the Pakistani Population. Asian Pacific Journal of Cancer Prevention, 14(10), 5625-5629.
- Sung JJY, Luk AKC, Ng SSM, Ng ACF, Chiu PKF, Chan EYY, Cheung PSY, Chu WCW, Wong SH, Lam TYT, Wong SYS (2021). Effectiveness of one-stop screening for colorectal, breast, and prostate cancers: A population-based feasibility study. Frontiers in Oncology; 11, 631666
- Suresh Pichandi, Palanisamy Pasupathi, Y Yagneswara Rao, Jawahar Farook, Babu Shankar Ponnusha, Athimoolam Ambika, Sathiyamoorthy Subramaniyam (2011). The effect of smoking on cancer – a review. Int J Biol Med Res. 2 (2), 593-602.
- Tarini Sinha, 2018. "Tumors: Benign and Malignant," Cancer Therapy & Oncology International Journal, Juniper Publishers Inc., 10(3): 52-54
- Wardle J, Robb K, Vernon S, Waller J (2015). Screening for prevention and early diagnosis of cancer. American Psychologist, 70(2), 119–133.
- World Cancer Research Fund International. WCRF International (2022). Worldwide Cancer Data Available online at: https://www.wcrf.org/cancer-trends/worldwide-cancer-data/ (accessed November 22, 2022).
- World Health Organization. (2022). Cancer. Who.int. https://www.who.int/news-room/fact-sheets/detail/cancer

ỌJỌ AJE

ETO: ẸKỌ BIBELI

JOSẸFU: AKOKO ATI IGBA RẸ

(Jẹnẹsisi 39-40)

ỌRỌ IṢAAJU:

Akoko ati igba jẹ abala pataki meji igbesi aye ti o n nipa lori iṣe wa ojoojumọ, iṣẹ wa ati imọlara wa. Akoko jẹ ohun ti a ko jọ ti o ran wa lọwọ lati ṣeto ati lati dari aye wa, nigba ti igba jẹ bi igba ṣe n yi, eyi ti o n mu awọn ohun ti a n la kọja wa. O ṣe pataki ki igba ati akoko ye wa lati le moriri bi aye ṣe ri. Iwe Atumọ Giriki damọran pe, a gbero akoko ati igba lati inu *Chronos*, eyi ti o tumọ si *akoko*, ati *Kairos*, ti o tumọ si *igba*. A ṣe ilana aye ti o jọ ara wọn debi pe igba ati akoko yoo maa wa. Wọn maa n yi ọpọlọpọ nnkan pada ninu aye eniyan. Ki àlá ati iran wa si imuṣẹ laye da le igba ati akoko. "Olukuluku ohun ni akoko wa fun ati igba fun iṣẹ gbogbo labẹ ọrun. Igba bibini, ati igba kiku, igba gbingbin ati igba kika ohun ti a gbin ...." (Oniwaasu 3:1-8), Gẹgẹ bi onigbagbọ, a gbọdọ mọ akoko ati igba lati le gbe igbesi aye ti o nitumọ.

ITAN JOSẸFU

Josẹfu jẹ ọkan ninu awọn ẹni ti a fẹran ninu Bibeli, a mọ ọn fun itan igbagbọ rẹ ti ko lafiwe, ipamọra ati idarijin rẹ. Itan rẹ jẹ ọkan ninu itan ti o wuni, ti o si jẹ imisi ninu Majẹmu Lailai, o si tẹsiwaju lati maa mi ni ọkan awọn onigbagbọ ni aye ode oni. Lati le jẹ ki ọrọ Josẹfu ati itan rẹ ye wa, o ṣe pataki ki a ni oye kikun nipa akoko ati igba ti o gbe. Josẹfu gbe lasiko darudapọ ninu itan awọn ọmọ Israẹli, akoko ti wahala wa ati ti ko si idaniloju. A bi i ni ilẹ Kenaani, oun ni ọmọkunrin kọkanla Jakọbu ati ọmọkunrin akọkọ ti ayanfẹ aya Jakọbu Rakaẹli bi fun un. Itan Josẹfu wa ninu iwe Jẹnẹsisi, o jẹ itan dídani, lilọ si oko-ẹru ati irapada.

A le tọpasẹ itan Josẹfu lọ sinu iwe Jẹnẹsisi ori kejila (12) nigba ti Ọlọrun pe Abrahamu sinu majẹmu ibaṣepọ pẹlu Rẹ, ti O si ṣeleri fun un. Josẹfu ni ọmọ ọmọ Abrahamu, ẹni ti Ọlọrun ṣe ileri alaini gbedeke fun lati pese ilẹ, orilẹ-ede ati ibukun fun irandiran rẹ. Jakọbu ati Rakẹli ni o bi Josẹfu. Wọn ta a si oko ẹru ni Egipti (Jẹnẹsisi 37) ni ẹni ọdun mẹtadinlogun (17) ni ogún owo fadaka (20). Ẹtan waye ni Datani. Iṣoro Josẹfu bẹrẹ laarin idile rẹ nitori pe baba rẹ Jakọbu fẹran rẹ ju awọn arakunrin rẹ yooku lọ, eyi ti o yọri si jijowu

Scanned with CamScanner

rẹ ati irunu laarin awọn ọmọ baba wọnyi. Awọn arakunrin Josẹfu ta a si oko-ẹru, wọn mu un lọ si Egipti, nibi ti Pọtiferi, agba ijoye ni agbala Farao kan ti ra a. Bi o tilẹ ti bọ si ipo miiran gẹgẹ bi ẹru onde, Josẹfu ṣi jẹ olotiitọ si Ọlọrun ati oluwa rẹ, ẹni ti o fi i si iṣakoso gbogbo ile rẹ.

Ṣugbọn sa, ọrọ Josẹfu yipada nigba ti aya Pọtiferi fi ẹsun eke kan an nigba ti o n gbiyanju ati fẹ ba a lò pọ̀. Wọn sọ Josẹfu sinu tubu, nibi ti o ti tumọ àlá awọn ijoye Farao meji. Talẹnti titumọ àlá rẹ ri akiyesi Farao ti ọkan rẹ ti poruuru nipa awọn àlá ti o lá ti n da a lọkan rú. Nipasẹ ìdásí ti ọrun, Josẹfu tumọ àlá Farao, asọtẹlẹ nipa ìyàn nla ti o fẹ bẹ silẹ ni ilẹ naa. Inu Farao dun si ọgbọn ati imisi ti Josẹfu ni debi pe o yan an gẹgẹ bi igbakeji rẹ ni ilẹ Egipti, o fun un ni iṣẹ ati pese orilẹ-ede naa silẹ fun iyàn ti n bọ. Agbara iṣakoso Josẹfu ati oju inu rẹ gba Egipti la kuro ninu ebi, awọn idile rẹ ni Kenaani naa pada wa maa gbe pẹlu rẹ ni Egipti. Itan Josẹfu jẹ majẹmu ti o lagbara si ipese ati iṣotitọ Ọlọrun, lasiko ti ọta doju ogun kọ ọ. Àlá Josẹfu wa si imuṣẹ. Josẹfu le lo akoko ati igba rẹ nipa sisọ iriri rẹ di ohun ti o yin Ọlọrun logo, eyi ti i ṣe ẹkọ fun awọn ọdọ ode oni.

AWỌN ẸKỌ FUN LILO

1. Pinpin awọn Ibukun Ọlọrun (Jẹnẹsisi 39:1-6)

Josẹfu jẹ ẹni to farajin si alaafia awọn arakunrin rẹ. Ni ọpọlọpọ igba, baba rẹ a ran an lọ si Hebroni, lati lọ gbe ounjẹ fun awọn arakunrin rẹ. Ki i rẹ̀ ẹ́ nigba kankan, bẹẹ ki i si i ṣaroye, dipo bẹẹ o maa n dide lati jiṣẹ, o si ka ibikita fun awọn arakunrin rẹ kún. Bi o tilẹ jẹ pe wọn korira rẹ, wọn si huwa buburu si i, o jẹ orisun ibukun fun wọn nigba ti wọn wa ra ounjẹ ni ilẹ Egipti. Josẹfu jẹ apẹrẹ onigbagbọ ti o yatọ, ti o gbẹkẹle Ọlọrun, ti o si lo awọn iṣẹlẹ ti o ṣẹlẹ si i daadaa.

2. Bibori awọn Idanwo Nla (Jẹnẹsisi 39:7-20)

Josẹfu dojukọ ewu nitori obinrin olojukokoro. Bibeli wi pe, "Nitori pe agbegbe, iho jinjin ni; ati ajeji obinrin, iho hiha ni" (Owe 23:27). Bi o ti wu ki awọn eniyan maa sọrọ nipa ibalopọ to, tabi ki wọn maa sọrọ gbe ki a ni ibalopọ ṣaaju igbeyawo ati ibalopọ laiṣe ninu igbeyawo, iriri yii ko ba Bibeli mu, ko tọ́, ẹṣẹ si ni, bẹẹni o si ni atubọtan. Panṣaga ati agbere maa n jẹ ki eniyan di ẹru si ẹṣẹ. Ohun ti o bẹrẹ bii "biba ara ẹni sọrẹ" yoo wa di nnkan olóró. Josẹfu ko ṣetan lati fi iwa mimọ rẹ ati iduro ṣinṣin rẹ ṣere lati le tẹ aya oluwa rẹ lọrun. Igboya nla ati ipinnu nla ni eleyii fun Josẹfu lati ja ogun naa ni ọjọ de ọjọ, eyi ti o si bori. O ṣalaye idi ti ko fi le gba fun un:

- Aya ọkunrin miiran ni, oluwa rẹ si ni ọkunrin naa.
- Oluwa rẹ ni igbẹkẹle ninu rẹ, ko si fẹ da igbẹkẹle naa.
- Koda gan-an bi o ba jẹ pe ko si ẹlomiran ti yoo mọ nipa rẹ, Ọlọrun yoo mọ, inu Rẹ ko si ni dun.

Ti o ba jẹ pe iwọ ni o wa ni ipo rẹ, kin ni o ko ba ṣe? Kiyesi pe, awọn igba kan wa ti o jẹ pe ti eniyan ba salọ o le dabi ẹni ti ẹru n ba a (Orin Dafidi 11:1-2; Nehemiah 6:11), awọn igba miiran si wa nigba ti sisalọ jẹ ẹri igboya ati iwa ọmọluabi. Josẹfu jẹ ọlọgbọn ti o tẹle imọran ti Pọọlu fun Timotiu, "maa sa fun ifẹkufẹ…" (Timotiu Keji 2:22a). Josẹfu gba lati padanu aṣọ ara rẹ ju aṣọ ti inu lọ. Gẹgẹ bi ọdọ Ajọ-nla Ijọ Onitẹbọmi Naijiria, ẹ jẹ ki a da yin mọ yatọ, ẹ sa fun gbogbo iwa iṣekuṣe nibikibi ti ẹ ba ti ba ara yin. Ikora-ẹni-nijanu jẹ koko pataki lati le ni iwa rere. Ranti eleyii pe: "Ẹni ti ko le ṣe akoso ara rẹ, o dabi ilu ti a wo lulẹ, ti ko si ni odi" (Owe 25:28).

Josẹfu ni ikora-ẹni-nijanu, ṣugbọn Samsoni lo ara rẹ lati mu ifẹkufẹ ara ṣẹ – igbadun. Josẹfu pari tirẹ si ori ìtẹ́, nigba ti Samsoni pari aye rẹ sibi ti o ti ku sabẹ àlàpà ogiri ile ti o wó.

3. Pipa Aiṣododo Mọra (Jẹnẹsisi 39:21; 40:23)

Josẹfu ṣiṣẹ takuntakun, a si gbe e ga si ipo igbẹkẹle ati aṣẹ. Ninu ipo tuntun naa, o wu aya Pọtiferi, o wa bi yoo ṣe fa oju rẹ mọra, nigba ti o si fi ọgbọn ati igboya kọ ọ, o jẹ ki wọn ti i mọ inu tubu. O ya ara rẹ sọtọ, lẹẹkan si i, a si fi ipo igbẹkẹle ti o tun ga julọ ṣe ere fun un. (Jẹnẹsisi 29:21-23)

4. Rireti ki Ọlọrun Ṣiṣẹ (Jẹnẹsisi 41:1-44)

Nigba ti o n reti ki Ọlọrun ṣiṣẹ, Josẹfu kii ṣe ọ̀lẹ, bi o tilẹ jẹ pe o la àlá ọjọ iwaju rere. Ọpọlọpọ awọn eniyan lode oni n reti pe ki Ọlọrun bukun fun awọn laisi ohunkohun ni ọwọ wọn. Bi Josẹfu ti tumọ ala Farao ati ayọrisi lẹyin imọran Josẹfu oju ẹsẹ ni o fun un ni ipo giga. Farao ronu pe ọkunrin ti Ọlọrun lo lati sọ iru iroyin yii ni yoo wa ni ipo ti o dara lati ṣe ojuṣe naa (Jẹnẹsisi 44:38-44). A gbe Josẹfu ga si ipo igbakeji si Farao funra rẹ. Igbega nla ni iru eleyii! Josẹfu kọkọ fi igba kan jẹ ẹlẹwọn, ni akoko miiran o di

Scanned with CamScanner

igbakeji ọba. Daju daju, eleyii jẹ ipo ti Ọlọrun ti ṣotẹlẹ fun Josẹfu ni ọpọlọpọ ọdun ṣeyin ninu àlá rẹ. Awọn arakunrin rẹ, ti wọn n jowu rẹ, fẹ da eto Ọlọrun fun igbesi aye rẹ rú, ko wa si ohun ti wọn le ṣe mọ ṣugbọn wọn tẹriba niwaju rẹ. O ṣe e ṣe ki o maa ya Josẹfu lẹnu bi awọn àlá naa yoo ṣe wa si imuṣẹ, paapaa lẹyin ti wọn ti tà á si oko-ẹru, ṣugbọn Ọlọrun gbe e ga nigba ti o ya. Ọlọrun pin iṣotitọ rẹ lere ni ọna ti o tayọ ohun ti eniyan le lero lọ. Bi o ti wu ki o pẹ to, awọn onigbagbọ gbọdọ maa reti pe ki Ọlọrun ṣiṣẹ, ki O si mu ete Rẹ wa si imuṣẹ ninu aye wọn. Josẹfu la ala ni ẹni ọdun mẹtadinlogun (17), o si wa si imuṣẹ ni ẹni ọgbọn (30) ọdun.

5. Idarijin ati Gbigbagbe Ohun ti O ti Ṣẹlẹ Latijọ (Jẹnẹsisi 41:46-57)

Iwa aṣemọ́ṣe awọn ẹgbọn Josẹfu pọ pupọ. Owú jíjẹ, ìlara, odì yíyàn, ìkorò ati ìkùnsínú ni o ṣokunfa iwa wọn si Josẹfu. Wọn fẹ ki o ku lẹyin ti wọn ti fi i ṣe ẹlẹya, ti wọn si ti gàn án. Ṣugbọn pẹlu gbogbo ayipada ile aye ti wọn sọ ọ si, Josẹfu duro ṣinṣin, o jẹ oniwa-bi-Ọlọrun. O darijin awọn arakunrin rẹ. Oore-ọfẹ pataki ni eleyii! Ko gbẹ̀san. Ẹkọ pataki ni eleyii fun wa gẹgẹ bi onigbagbọ lode oni (Owe 16:7).

Ọrọ Ipari

Pẹlu gbogbo iwakiwa ti awọn arakunrin Josẹfu fi huwa si i, ko huwa ìkorò si wọn tabi fi ẹ̀san da wọn lohun. Josẹfu dojukọ idanwo ti aya Pọtiferi mu wa, ṣugbọn ko yago kuro ninu ṣiṣẹ ohun ti o tọ́. Bakan naa, wọn fi ẹsun èké kan Josẹfu, sibẹ eleyii ko mì ín, koda gan-an ati igba ti wọn ju u sinu tubu. Josẹfu tun gbẹkẹle agbara Ọlọrun eyi ti o jẹ ki o yẹ fun ojuṣe naa. Kii ṣe pe wọn kan fun un ni ipo nla ni Egipti lasan, o fi ara rẹ han bi ẹni ti o yatọ. Gẹgẹ bi ọdọ, ni ipo ni Ọlọrun fi ọ si, boya lẹnu iṣẹ rẹ, nibi ti o ti nitaja, lẹnu oko-owo tabi ile iwe, lo anfaani akoko ati igba ọdọ rẹ daadaa.

Awọn Iwe Itọkasi

- Warren W. Wiershbe. (2015). Be Authentic. USA: David Cook International Publisher.
- The Holy Bible: New King James Version. (1975). Harpercollins Publishers.
- Claus Westermann Commentary. (1982). Minneapolis: Augsburg Publishing House.
- The Holy Bible: New Century Version. (1991). Thomas Nelson Publishers.

ỌJỌ ISEGUN

AKOKO ADURA

IDARI FUN ADURA

JADE LỌ!

DEUTARỌNỌMI 1:1-8

ỌRỌ IṢAAJU

Denzel Washington sọ pe, "A ko gbọdọ ṣi sisun kuro mu fun lilọ siwaju." Gbolohun yii duro fun pe o ṣe e ṣe fun eniyan lati kuro ni ibi kan lọ si ibomiran, sibẹ ki o ma ni ilọsiwaju. Eleyii ni ọrọ awọn ọmọ Israẹli ni Ori Oke Horebu. Awọn eniyan Ọlọrun sọ afojusun ibi ti Ọlọrun ti ṣeleri fun awọn baba nla wọn nu. Okan won bale ni Horebu nigba ti Ọlọrun ni ibi ti o sàn, ti o si ga ju bẹẹ lọ fun wọn ni iwaju. Idi niyi ti Oluwa fi sọ fun wọn ni Horebu pe, "*Ẹ gbe ori oke yii pẹ to. E ya yipada ki e si mu ona yin pọn, ki ẹ si lọ si oke awọn ọmọ Amori…*" (*Deutarọnọmi 1:6-8*). Bakan naa, Olorun ko fẹ ki awọn ọmọ Rẹ duro si oju kan tabi ki wọn maa rare kaakiri laini ilosiwaju. Nitori naa, afojusun adura yii ni lati kede aṣẹ ti ọrun fun ilọsiwaju ni awọn abala aye wa gẹgẹ bi onigbagbọ ninu Kristi.

ILANA ADURA

A. **Kin ni O Tumọ si lati Jade Lọ?**
Gẹgẹ bi Iwe Atumọ ede *Advanced English Dictionary* se so, oro yii "Jade Lọ" tumọ si yiyọ jade kuro ninu ọgba ẹwọn. O tun tokasi sisa jade kuro ninu ibi ti idena wa tabi ibi ti a fi eniyan pamọ si. Eyi tumo si pe jijade kuro ni wiwa ominira kuro ni ipo ati ninu awọn nnkan ti o n fi eniyan sinu ide tabi si ọgba ẹwọn. Lati inu ibi ti a ka fun ayẹwo, oro yii 'jade lo' je ase ti ọrun tabi iyanju fun awọn ọmọ Israẹli ti wọn ti duro pe ni Horebu (Deutarọnọmi 1:7). Idi ti awọn onigbagbọ fi ni lati te siwaju si ipele miiran, ki wọn le de Ilẹ Ileri ni o ṣokunfa aṣẹ ti ọrun yii. Nitori naa, o se pataki fun awọn ọmọ Ọlọrun lati mọ pe ifẹ Baba wa ọrun ni pe ki won maa tesiwaju ni aye ati ninu ayanmọ wọn. Ohun ti o ba yato si eleyii lodi si igbekale Olorun fun aye wa lati ibẹrẹ pẹpẹ. Idi niyi ti a fi nilo imo ati adura takuntakun lati jade lo kuro ninu ohunkohun tabi ipokipo ti n so wa mole tabi fa wa seyin ni aye.

B. **Awọn Igbesẹ lati gbe lati Jade Lo**
Ni ibamu pẹlu ibi asayan Bibeli wa ti a ka, awọn nnkan wonyi ni awon igbesẹ ti a le gbe lati jade lọ kuro ninu awọn nnkan tabi ipo ti n dena itẹsiwaju ile aye eniyan:

Scanned with CamScanner

i. **Kọ́ lati Gbọ́ lati Ọdọ Ọlọrun:** "*Oluwa Ọlọrun wa sọ fun wa ni Horebu … (Deutarọnọmi 1:6)* Igbesẹ akọkọ lati jade lo ni lati kọ bi a ṣe n gbọ ohùn lati ọdọ Ọlọrun. Awọn eniyan Ọlọrun ko mọ pe awọn ti duro pẹ pupọ ni Horebu titi di igba ti Ọlọrun fi sọrọ fun wọn nipa rẹ. Iṣẹ Ọlọrun si awọn eniyan Rẹ ni ibi ibẹrẹ ọna abayọ wọn. Lati maa tẹsiwaju, eniyan gbọdọ gbe oore-ọfẹ lati gbọ lati ọdọ Ọlọrun ró loorekoore.

ii. **Ẹ Kọju Ija si Nini Itẹlọrun Loju Kan:** "*… Ẹ gbe ori oke yii pẹ tó*" (Deutarọnọmi 1:6). Igbesẹ pataki miiran lati maa tẹsiwaju ni lati ba ẹmi tabi iṣe nini itẹlọrun loju kan ja: nini itẹlọrun pẹlu nnkan kekere. Ọlọrun tu awọn ọmọ Israẹli silẹ ni Egipti, ati ninu irin-ajo lọ si Kenaani. Nitori itẹlọrun diẹ ti wọn n gbadun ni Horẹbu, itẹlọrun de ba wọn. Bakan naa, ọpọlọpọ awọn eniyan kii ronu nipa itẹsiwaju nibi ti wọn ba ti n gbadun itẹlọrun diẹ. Awọn onigbagbọ gbọdọ kọyin si nini itẹlọrun diẹ, ṣugbọn ki wọn ṣiṣẹ tọ ilọsiwaju gẹgẹ bi Apọsteli Pọọlu (Filipi 3:10-14).

iii. **Ẹ Yipada (Ẹ Yapa):** "*Ẹ yipada, ki ẹyin si mu ọna yin pọn, ki ẹ si lọ si oke awọn ọmọ Amori …" (Deutarọnọmi 1:7)*. Lati tẹsiwaju, eniyan ni lati mọ-ọn-mọ ya kuro ninu ohunkohun ti n de e mọlẹ. Fun awọn ọmọ Israẹli, ipagọ ati inu agọ ti wọn kọ fun ara wọn ni wọn ti so ara wọn mọ. Wọn ko ṣetan lati jade kuro ni ibi itura ti wọn kọ fun ara wọn, eyi si jẹ idena fun ilọsiwaju wọn fun igba pipẹ. Bakan naa, awọn Kristiani gbọdọ ṣetan lati jade lo kuro ninu aye, iwa ẹṣẹ, ibaṣepọ ti ko tó, awọn nnkan atijọ ti a n wo bi ohun ti o ṣe iyebiye ati lati ibi itura wa. Lati dawọle nnkan nla ti o wa niwaju, eniyan gbọdọ fi awọn nnkan kan si ẹyin (Filipi 3:7-8).

iv. **Ẹ Gba awọn Ilẹ Tuntun:** *"… ati si gbogbo agbegbe rẹ, ni pẹtẹlẹ ni ori oke, ati ni afonifoji, ati ni iha gusu, si ilẹ awọn ara Kenaani, ati si Lẹbanoni, de odo nla ni, odo Euferate" (Deutarọnọmi 1:7)*. Awọn ọmọ Israẹli ko rii pe awọn ilẹ tuntun wa niwaju wọn titi ti Ọlọrun fi ba wọn sọrọ. Ni ọna kan naa, awọn onigbagbọ gbọdọ mọ pe ohun ti o pọ wa niwaju wọn, eyi si pe fun ki a lọ ṣawari rẹ. Eyi le tumọ si pe ki a gbiyanju ohun tuntun, ki a wa imọ tabi ero tuntun, ki a lo ilana tuntun lati ṣe nnkan ti a ti n ṣe tẹlẹ, ki a lọ fun ẹkọ siwaju sii tabi ikọ́ṣẹ́, ki a jẹ alagbara ti o mọ ohun ti n ṣe dunjúdunjú, ki a jẹ ọlọgbọn atinuda ati alailafiwe ninu ohun ti a n ṣe. Tori naa, a gbọdọ maa tẹsiwaju lati ṣawari titi ti a o fi ri ayipada ti a n fẹ.

v. **Ẹ Gba awọn Ogun Ini Yin**: *"Wo o, mo ti fi ilẹ naa siwaju yin; ẹ wọ ọ lọ ki ẹ si gba ilẹ naa ti Oluwa bura fun awọn baba yin…" (Deutarọnọmi 1:8*). Ọlọrun ti fun awọn ọmọ Rẹ ni idaniloju pe tiwọn ni ilẹ naa. Nitori naa, o ku si ọwọ wọn lati gba ilẹ ti o jẹ tiwọn. Ibi ti adura ti di dandan niyi gẹgẹ bi Kristiani. Pẹlu adura gẹgẹ bi irinṣẹ, ọmọ Ọlọrun le jade

kuro ninu idena, ki o si tẹsiwaju. Awọn onigbagbọ le gba gbogbo ogun ini wọn ni ti ẹmi, ti ara ati ti ohun-elo nipa adura igbagbọ.

D. Adura fun Ọna Abayọ Ara-ẹni ati Lapapọ

ADURA ARA-ẸNI

1. Dupẹ lọwọ Ọlọrun fun itẹsiwaju ti o ti ni iriri rẹ ninu irin-ajo aye rẹ. Dupẹ lọwọ Rẹ fun ibi ti o ti n bọ, ibi ti o de bayii ati ibi ti O n mu ọ lọ.
2. Dupẹ lọwọ Ọlọrun fun itusilẹ rẹ kuro ni Egipti ni ọna iyanu, ati ileri Rẹ ti o daju lati mu ọ lọ si Ilẹ ileri rẹ, bi o tilẹ jẹ pe, ileri Rẹ le pẹ, moriri Rẹ nitori pe o daju pe yoo wa si imuṣẹ.
3. Jẹwọ gbogbo ẹṣẹ rẹ, eyi ti o mọ ati eyi ti o ko mọ ti o le dena ki adura rẹ ma jẹ itẹwọgba niwaju Ọlọrun. Beere ki aanu Rẹ bori ninu aye rẹ.
4. Beere fun oore-ọfẹ lati wu Oluwa gẹgẹ bi ọmọ Rẹ ni igba gbogbo, ki o ma dabi awọn ọmọ Israẹli alagidi ati ọlọtẹ.
5. Gbadura wi pe ki orisun ẹmi rẹ ṣi lati le maa gbọ lati ọdọ Ọlọrun loorekoore. Beere pe ki Ọlọrun ba ọ sọrọ ni igba gbogbo, ki O si fi imọran Rẹ han fun aye rẹ.
6. Gbadura tako ẹmi ati iṣe nini itẹlọrun loju kan ti o le fẹ dena rẹ ni aye. Beere pe ki ọkan rẹ ma balẹ tabi ni itẹlọrun pẹlu ohun kekere titi ti o o fi de ibi ti o n lọ.
7. Beere fun igboya ati igbẹkẹle lati ọdọ Ọlọrun lati jade kuro ninu ibi itura rẹ. Gbadura fun agbara lati gbe igbesẹ ati lati ṣe ohun ti yoo mu ọ lọ si ipele ti o kan ni gbogbo isọri aye rẹ.
8. Beere pe ki Ẹmi Mimọ ran ọ lọwọ lati jade kuro ninu aginju, iwa ẹṣẹ, ajumọsepọ buburu, awọn nnkan atijọ ti o ka kun nnkan iyebiye, awọn iwa buburu ti o ti dena ilọsiwaju rẹ fun igba pipẹ.
9. Kede ominira rẹ kuro ninu ibi ide tabi idena ti o ba ara rẹ. Beere pe ki Ọlọrun sọ ọ di ominira kuro ninu awọn agbara ati majẹmu ti o ti fi ọ sinu ide.
10. Beere pe ki ẹmi titayọ ba le ọ ati ohun gbogbo ti o jẹ tirẹ. Gbadura fun ọgbọn ati imisi lati ṣawari awọn ilẹ tuntun, ki o si mu iyatọ wa ni agbegbe rẹ.
11. Beere pe ki ọrun rẹ ki o ṣi lati le ni iriri ọna abayọ alailodiwọn ni ọdun yii.
12. Pẹlu aṣọtẹlẹ, beere lati gba ohun ini ati ogun ini rẹ ninu Kristi Jesu. Paṣẹ, ki o si beere fun awọn ibukun ni ẹmi, ara ati ninu ohun ini sinu aye rẹ ati ti idile rẹ.
13. Beere pe ki Oluwa fi opin si ifarahan ati iriri diduro soju kan ati ijakulẹ ninu aye rẹ. Pẹlu asọtẹlẹ, paṣẹ pe ki opin de ba ifasẹyin ati jijẹ ero ẹyin ni ọnakọna lagbegbe rẹ.
14. Gbadura fun igbesoke ti ọrun ati lilọ siwaju bi o ṣe n rin irin ajo ti ọdun yii. Beere pe ki ọwọ Ọlọrun gbe ọ lọ si ipele ti o tayọ agbara ati ero ẹda.

Scanned with CamScanner

15. Beere lati akoko yii lọ pe ki o ni iriri agbara ti ọrun ati itẹsiwaju ati gbigbooro ni gbogbo iha aye rẹ kiakia.

ADURA FUN GBOGBO-GBOO/GBOGBO WA LAPAPỌ

16. Ẹ beere pe ki Ọlọrun bukun fun wa loorekoore gẹgẹ bi ijọ, ajumọṣe, ajọ ipinlẹ ati Ajọ-nla. Ẹ gbadura fun oore-ọfẹ lati jẹ olugbọran si Ọlọrun bi O ṣe n ba wa sọrọ.
17. Ẹ gbadura wi pe a ko ni ni itẹlọrun ni oju kan ninu ẹmi, iṣẹ isin ninu ọgba ajaara ati ninu pipolongo ihinrere Kristi ni akoko opin aye yii.
18. Ẹ beere pe ki Ọlọrun fi ebi ati gbe igbesi aye ododo pa wa, ki a le poungbẹ fun awọn ọkan ti n ku lọ, ki amugbooro ijọba Ọlọrun le wa sinu ọkan gbogbo ọmọ Ijọ Onitẹbọmi: awọn ọmọde, ọdọ langba/ọdọ ati awọn agba.
19. Ẹ beere lọwọ Ọlọrun fun igboya ati agbara gẹgẹ bi ijọ lati jade kuro nibi itura wa ki a le mu ihinrere Oluwa wa Jesu Kristi de aarin awọn eniyan ti ko tii de.
20. Ẹ beere pe ki Ẹmi Mimọ tu awọn ọdọ wa silẹ kuro ninu ẹran ara, aye, ati igbakoso satani ti o le mu wọn padanu ogun wọn ninu Kristi.
21. Ẹ gbadura wi pe ki Oluwa gba awọn ti wọn wa labẹ ide iwa baraku kan tabi omiran pẹlu hihu iwa ibajẹ ati awọn iwa buburu miiran silẹ bii: iṣekuṣe, wiwo aworan ihoho, lilo ogun olóró, ìmutí para, ẹgbẹ okunkun ati ṣiṣe ogun owo.
22. Ẹ beere pe ki ẹmi titayọ ba le awọn adari wa ni gbogbo ipele. Ẹ gbadura fun ọgbọn ati imisi lati ṣawari awọn ilẹ tuntun ninu iṣẹ-iranṣẹ ati pe ki O fun wa ni oore-ọfẹ lati da yatọ ninu awọn ijọ wa.
23. Ẹ paṣẹ ominira kuro ninu ide tabi idena ti a ba ara wa gẹgẹ bi iṣẹ-iranṣẹ. Ẹ beere pe ki Ọlọrun bẹ ijọ wa wo pẹlu agbara ọrun Rẹ fun ominira kuro ninu igbekun.
24. Ẹ pa a laṣẹ pe ki awọn agbara, iṣe ati iṣẹ okunkun ti o n fa ifaseyin dawọ duro ni orukọ Jesu.
25. Ẹ beere pe ki Ọlọrun fi opin si iduro soju kan ati ifaseyin ni ibikibi ninu awọn ijọ, ajumọṣe, ajọ ipinlẹ ati Ajọ-nla lapapọ.
26. Ẹ beere pe ki awọn ọdọ wa maa goke kiakia bi wọn ṣe n lepa ẹkọ, iṣẹ ayanlaayo, ninu ọrọ igbeyawo, iṣẹ-iranṣẹ ati ayanmọ wọn.
27. Ẹ beere fun ọna abayọ alailafiwe ninu awọn ijọ, ajumọṣe, ajọ ipinlẹ ati Ajọ-nla ni iha gbogbo.
28. Ẹ paṣẹ, ki ẹ si kede pe ki gbogbo ibukun ti ẹmi, ara ati ohun ini de ba iṣẹ Ijọ Onitẹbọmi ni Naijiria ati tayọ ibẹ ni orukọ Jesu.
29. Ẹ gbadura wi pe lati akoko yii, ijọ Onitẹbọmi yoo ni iriri itẹsiwaju ti ọrun ati ni awọn ọna miiran ni iha gbogbo nile aye kiakia.
30. Ẹ dupẹ fun idahun adura. Ẹ bukun fun orukọ Rẹ nitori pe yoo ṣe ju ohun ti a le beere tabi ro lọ nipasẹ Kristi Oluwa wa.

ỌJO 'RU

ETO: ERE ITAGE/ETO APEJỌPỌ ORIN KIKỌ

ABALA KINNI

**A ri Ẹlẹdaa lori itage pẹlu awọn ẹda Rẹ meji.*

ẸLẸDAA: (*O n ba awọn ẹda meji sọrọ*). Ẹ ni lati lọ. O ṣe pataki pe ki ẹ lọ si ilẹ ti mo ti pese lati le jẹ ki majẹmu ti mo ṣe pẹlu awọn baba yin le di mimuṣẹ. Ibẹ jinna ju ibi ti ẹ wa bayii lọ. Eto ti mo ni fun yin jẹ eto ti o pọ, wọn ko si ni le wa si imuṣẹ ti ẹ ba ṣi wa nibi. Ẹ ni lati lọ. Ẹ lọ si ilẹ ti a n pe ni 'Ilu Iṣura.'

Ẹda Kinni: (*O da si i*) ẸLẸDAA, kii ṣe pe a ko ṣe daadaa nibi, tabi ebi n pa wa, bẹẹni a ko jiya nibi ti a wa bayii. Kin wa lo de ti Ẹ fi fẹ ki a lọ sibi ti a ko mọ ohunkohun nipa rẹ. A ko tilẹ mọ bi o ṣe ri tabi ibi ti o wa lori atẹ aworan agbaye. A ko tilẹ mọ ohunkohun nipa rẹ....

ẸLẸDAA: (*Pẹlu ohùn irẹlẹ*) Ọmọ mi, ti o ba jẹ pe o mọ eto ti mo ni fun awọn baba yin ni. Mo n ran yin lọ sibẹ nitori pe mo mọ ohun ti o wa nibẹ. BẸẸNI, ẹ o dojukọ awọn ipenija ninu irin-ajo yin, ṣugbọn ẹ maṣe bẹru. Ti ibẹ ko ba dara, n ko ni ran yin lọ sibẹ. Ẹ ko ni lati ṣe aniyan nipa ohunkohun, ohun gbogbo ti ẹ o nilo wa ninu àpótí ti n o gbe fun ẹni kọọkan yin. O wa gbe apoti meji jade, o si fun ẹni kọọkan wọn ni ọkọọkan).

Ẹda Keji: (*O mí kanlẹ*). A gbagbọ pe Ẹ mọ ju bi a ṣe mọ lọ, a si gbẹkẹle ipinnu Yin. Ti o ba jẹ pe lilọ si Ilu Iyebiye ni ohun ti o dara julọ fun wa bi Ẹ ṣe sọ, a jẹ pe a o lọ.

*ẸLẸDAA ran wọn leti pe ohun gbogbo ti wọn nilo wa ninu àpótí ti O gbe fun ẹni kọọkan wọn bi awọn ẹda mejeeji ṣe fẹ maa jade lọ, o tẹsiwaju pe nigbakiigba ti wọn ba n poruuru ọkan tabi ti wọn ko mọ ọna mọ, ki wọn ṣi àpótí naa, wọn yoo si ri ọna abayọ.

IRAN KEJI

*Ọkunrin kan ti o lẹ 'Ẹtan' mọ igbaaya rẹ bọ si ori itage pẹlu ọla nla rẹ pẹlu ọpọlọpọ ẹbun ti o jẹ oju ni gbese ti o so mọ ara. Tayọtayọ ni o n sọrọ bi awọn ẹda mejeeji ṣe n rin sunmọ ọdọ rẹ.

Scanned with CamScanner

Ẹda Kinni: (*O n ba ẹda keji sọrọ*). Kin lo de ti irin ajo yii ṣe n mu aarẹ wa, ti o si n su eniyan bayii? Eleyii ko si lara eto wa. A ti rin fun ọpọlọpọ ọjọ ati oru, a ko si tii de Ilu Iṣura ti ẸLẸDAA sọrọ nipa rẹ. Njẹ o tumọ si pe ẸLẸDAA kan mu wa wa sibi lati jiya ni?

Ẹda Keji: (*O da si i*). Lootọ ko ye mi idi ti ẸLẸDAA ṣe e eleyii fun wa. Ohun ti o buru ju ni pe a ko mọ ọna pada si ibi ti a ti n bọ, a ko si mọ bi irin ajo yii yoo ṣe gba wa pẹ to de Ilu Iṣura.

*(*Bi awọn ọkunrin mejeeji ṣe n jiroro, awọn mejeeji ṣakiyesi ẹtan ti o duro sunmọ ọdọ wọn. Wọn sunmọ ọn, wọn si beere ẹkunrẹrẹ alaye nipa Ilu Iṣura ati bi wọn ṣe le de ibẹ*).

Ẹda Kinni: Hello; ẹ jọwọ, alejo ni wa nibi, a nilo idari yin lọ si oju ọna ti o lọ si ẹnu ọna Ilu Iṣura. O dabi pe a ti sọnu, a ko si mọ ibi ti a le ya si.

Ẹtan: Oh, mo ri i pe alejo ni yin. Dajudaju, n o ran yin lọwọ nipa didari yin si Ilu Iṣura ṣugbọn yoo na yin ni nnkan.

Ẹda Keji: Bi o ṣe ri i, a ko mọna mọ, a ko si ni ohun ti a le fun ọ tabi san fun ọ. Koda gan-an, diẹ lo ku ki a dákú, ebi si n pa wa, bẹẹni orugbẹ n gbẹ wa.

Ẹtan: Ẹ maṣe da ara yin laamu. (O tọka si àpótí ti o wa lọwọ awọn ẹda mejeeji) Ẹ ni nnkan ti ẹ le fi san owo. Ti ẹ ba le gbe apoti ọwọ yin fun mi, n o si nawọ́ Ilu Iṣura naa fun yin, emi naa o si fun yin ni apoti pẹlu kọkọrọ ti ẹ o fi ṣilẹkun ibẹ.

Ẹda Kinni: Oh, ẸLẸDAA ko tilẹ sọ fun wa pe a nilo kọkọrọ lati ṣi ẹnu ọna. Abi ẹ ẹ ri nnkan!!! Ko si iṣoro kankan sir! Kii ṣe pe a n lo apoti naa. Ẹ le gba a.

**Awọn ẹda mejeeji gbe apoti naa fun Ẹtan ni paṣipaarọ, o gbe apoti miiran fun ọkọọkan wọn. O kilọ fun wọn pe nigba ti wọn ba ti rin jinna rere ni ọna ti yoo dari wọn gba ni ki wọn to ṣi apoti naa.*

Lẹyin ti wọn ti rin fun igba diẹ, awọn ẹda mejeeji pinnu ati ṣi apoti, wọn si rii pe ofifo ni o wa. Ijakulẹ ba wọn, ikoro si wa ni ọkan wọn. Ṣugbọn wọn tẹsiwaju ni ọna naa ti o tọka fun wọn, bi o tilẹ jẹ pe o ti rẹ wọn.

IRAN KẸTA

**A ri ọkunrin kan lori itage ti n ṣowo ẹrú. O n ba wọn sọrọ, o n kilọ fun wọn lati maṣe jẹ ọlẹ lori oko rẹ, bẹẹni wọn ko si gbọdọ jẹ eso kankan ni oko rẹ tabi mu ohunkohun titi ti wọn yoo fi pari iṣẹ ọjọ naa.*

Bi o ṣe fẹ kuro ni oko, a ri awọn ẹda mejeeji ti wọn n rin sunmọ wọn, o si ti rẹ wọn, irin ajo naa ti sú wọn. Wọn yara sare lọ si ọdọ oniṣowo ẹrú yii.

Ẹda Kinni: Ẹ pẹlẹ sir! Ẹ jọwọ ajoji ni a jẹ ni ilẹ yii. A si n lọ si Ilu Iṣura, a si ti wa ni ẹnu irin ajo yii tipẹ. A ti ṣìnà.

Ẹda Keji: (*O sọrọ sita*). Koda gan-an, a ti jiya pupọpupọ ninu irin ajo yii. A pade ọkunrin kan ni ọjọ meloo kan sẹyin ti o tàn wa, o fi ọgbọn arekereke gba awọn apoti ti a gbe lọwọ, o si gbe ofifo apoti fun wa lati paarọ tiwa. Ohun ti o buru ju ni pe a ko tilẹ mọ ọna ati pada si ọdọ ẸLẸDAA ti a ti n ti n bọ mọ ti a ba tilẹ fẹ pada . Ẹ jọwọ sir, ẹ ran wa lọwọ.

Oniṣowo Ẹrú: Ko si iṣoro rara. Tori pe aanu yin ṣe mi, ati ninu aanu mi, n o dari yin si ẹnu ọna Ilu Iṣura funra mi, n o si dari yin pada si ọdọ Ẹlẹdaa.

**Awọn ẹda mejeeji di mọ ara wọn pẹlu ayọ, wọn si dọbalẹ fun oniṣowo ẹru.*

Oniṣowo Ẹrú: (*O n rin ẹ̀rín ìyàngì, o si gbe ohùn rẹ soke*) Ṣugbọn, ẹ o ni lati ṣiṣẹ fun mi fun akoko diẹ fun aanu ti mo fẹ ṣe fun yin yii. Bakan naa, n o gba apoti ọwọ yin, ki ẹ le ṣiṣẹ daadaa.

Ẹda Kinni: Hẹn! hẹn! Ti o ba jẹ ki a ṣiṣẹ fun ọ ni fun igba diẹ ati ki a gbe awọn apoti ọwọ wa fun ọ nikan ni ohun ti a nilo lati ṣe fun ọ ti yoo mu wa de Ilu Iṣura, a ti ṣetan.

**Oniṣowo ẹrú gba awọn apoti ọwọ wọn, o si ko wọn jade lọ.*

IRAN KẸRIN

**ẸLẸDAA fi ara han fun wọn loju ala, inu rẹ bajẹ, o si n ṣaroye …*

ẸLẸDAA: Oh!!! Ẹyin ọmọkunrin mi, di igba wo pẹ to ni ẹ o maa fi oore-ọfẹ ati ogo mi ṣofo. Mo ran yin jade, kii ṣe nitori pe n ko le bikita fun yin nibi, ṣugbọn nitori pe mo fẹ ohun ti o dara julọ fun yin. Mo ko ọpọlọpọ ohun ini pamọ fun yin, mo si fun yin ni ohun gbogbo ti ẹ nilo fun irin ajo yii ṣugbọn lọfẹẹ lofo ni ẹ gbe e fun Ẹtan, eleyii si

Scanned with CamScanner

ti mu yin lọ si oko-ẹru. Ojútì gbaa ni eleyii! Di igba wo ni ẹ o maa tẹsiwaju lati jẹ ẹrú ni ilẹ ajoji? Di igba wo ni ẹ o fi tẹsiwaju lati maa fi akoko ṣofo? Ẹ gbagbe nipa mi, ẹ ko si pe mi ninu gbogbo irin ajo yii. Mo lero pe ẹ o jade kuro, ẹ o si gba ilẹ ti mo pese silẹ fun yin. Ilẹ ti mo fun awọn baba yin ki a to loyun yin.

IRAN KARUN-UN

Onișowo Ẹrú: (*Pẹlu ibinu o n ba awọn Ẹda mejeeji sọrọ.*) Ẹ ti ṣiṣẹ fun ọdun meje nibi, n ko si tii ri ipa iṣẹ yin. Ẹ tun ni lati lo ọdun meje miiran ki n to ba yin lọ si Ilu Iṣura. Ṣugbọn ti ẹ ba lero pe ẹ le lọ laisi mi, ẹ maa lọ ṣugbọn mo mọ daju pe ẹ ko le lọ.

Ẹda Kinni: (*O n sunkun, o si ti rẹ ẹ.*) O ti sú wa lati duro sibi. A ti sin ọ pẹlu akoko ọdọ wa lai ko ohunkohun jọ. O n ṣe wa bi ẹru ṣugbọn o sọ pe a kan n ran ọ lọwọ ni, ki o le tete yara tẹle wa, ki o si ba wa lọ si Ilu Iṣura. O ti to akoko bayii fun wa lati lọ. A ti duro pupọ ju nibi. O ti fi akoko, agbara ati akoko ọdọ wa ṣofo, o si tun n sọ fun wa pe ki a tun ṣiṣẹ fun ọdun meje miiran. A o lọ si irin ajo laisi iwọ nibẹ. A o lọ ninu ifẹ Ẹlẹdaa wa.

(*O kigbe ni ohùn rara*) ẸLẸDAA, a kabamọ o!!! A ti padanu idari wa, a ti sako lọ, a ti kuro ninu ifẹ Rẹ. A gbe ẹbun iyebiye wa ti O fun wa fun Ẹtan. Wa gba wa la. A ṣetan lati jade sita. A ṣetan lati gba ilẹ ti o jẹ tiwa.

**Gbogbo wọn rin jade lọ bi wọn ṣe n kọrin.*

OPIN ERE

ỌJỌ 'BỌ

IKỌNI

IBARA-ẸNI-ṢỌRẸ TI O DA LE ETE KAN

ỌRỌ IṢAAJU

Ibara-ẹni-ṣọrẹ ṣe e ṣe nigba ti ẹ ba ni iran ati itara kan naa. Fun awọn onigbagbọ ninu Kristi, bi o tilẹ jẹ pe iyatọ lọpọlọpọ wa ninu ipo, ninu iṣe, aṣa, iran, ijafafa ati itan ara ẹni, ohun kan wa ti o wọpọ ti o lagbara ju gbogbo wọn lọ. Gẹgẹ bi iwe Atumọ Ede *Merriam Webster Dictionary* ṣe sọ, a tumọ nini ete tabi afojusun gẹgẹ bi ipo nini ete ti o nitumọ, nigba ti jijẹ ọrẹ si tumọ si ipo jijẹ ọrẹ, ibaṣepọ ti o wa laarin awọn ọrẹ. Jijẹ ọrẹ ti o da le ete kan tabi afojusun jẹ erongba ti o jinlẹ ninu ẹkọ Bibeli, ti o n ṣatẹnumọ iṣepataki ati asopọ ojulowo ti a mọ-ọn-mọ ṣe. Ni aye ti asopọ ko ti ja mọ nnkan kan, ṣiṣe ọrẹ ti o ni afojusun duro bii erongba ti ko ni akoko ati ti o jinlẹ.

Ipilẹ rẹ wa ninu ẹkọ Bibeli, jijẹ ọrẹ ti o da le ete ti o tayọ ibara-ẹni-kẹgbẹpọ lasan, o fi ifẹ, idanilọkanle ati iṣiro han. Iṣepataki ibara-ẹni-ṣọrẹ wa ninu itọkasi Bibeli eyi ti a fi han nipasẹ ọgbọn ti o dari asopọ ti o ni itumọ. Dafidi ati Jonathani jẹ ọrẹ ti o jinlẹ. Jijẹ ọrẹ Elijah ati Eliṣa jẹ eyi ti o ni agbara ati mu wa dagba. Jijẹ ọrẹ Rutu ati Naomi waye nitori ijamba. Lara awọn miiran ni Pọọlu ati Timotiu, Maaku ati Pọọlu, Johanu ati Jesu Kristi, Mose ati Aaroni pẹlu Abrahamu ati Lọti, lati mẹnuba diẹ.

Ọrọ ti wọn saba maa n lo ninu ṣiṣe ọrẹ ni philos [*Phileo*], "ọrẹ," ati *adelphos [ajdelfov]/adelphe.* Ninu majẹmu mejeeji, ọrọ ọrẹ ati jijẹ ọrẹ pe fun awọn nnkan mẹta, ajumọṣe, iṣolotiitọ ati ififẹhan sira ẹni. O le jẹ bi o ṣe fi han pe o jẹ ọrẹ si ni nnkan ti ẹlomiran nilo. Ti mo ba le beere, ta ni o o ba ṣe ọrẹ lonii?

IPILẸ JIJẸ ỌRẸ NINU BIBELI

Jijẹ ọrẹ ni ipilẹ rẹ ninu iwe mimọ ati awọn ẹsẹ Bibeli. Iwe Owe 17:17 sọ pe, "Ọrẹ a maa fẹni nigba gbogbo, ṣugbọn arakunrin ni a bi fun igba ipọnju." Ẹsẹ yii fi ipilẹ mímọ̀-ọ́n-mọ̀ jẹ ọrẹ han, ti o fi ifẹ han bii agbara ti a ko le yẹ kuro, ohun ti o wu ki o ṣẹlẹ. Ni afikun, Owe 18:24 ṣatẹnumọ bi ọrẹ gidi ṣe le sunmọni ju arakunrin lọ han, eyi ti n ṣatẹnumọ ijinlẹ ati iṣolotiitọ ohun ti jijẹ ọrẹ tootọ pe fun.

AWỌN ABUDA MÍMỌ̀-Ọ́N-MỌ̀ JẸ ỌRẸ

A. ***Ifẹ ti Ko Mọ Tara Ẹni:*** Pẹlu imisi itumọ ti Bibeli fun ifẹ ninu Kọrinti Kinni 13:4-7, mímọ̀-ọ́n-mọ̀ jẹ ọrẹ pe fun aimọtara-ẹni, ifẹ irubọ ti o tayọ gbedeke kankan. Ifẹ ni o ṣe aworan nnkan ti ọrun, ti o ṣafihan ifẹ si awọn ọmọ Rẹ. Pẹlu imisi lati inu ifẹ inu Bibeli, ṣiṣe ọrẹ ti o da le ete kan pato pe fun irubọ ati ifẹ ti ko rọ mọ ohunkohun fun ẹlomiran, ifẹ ti o da le ete maa n yọ fun ohun ti ẹni kọọkan ba gbe ṣe, aṣeyọri ati ibukun. Owe 17:17 sọ pe

Scanned with CamScanner

'Ọrẹ a maa fẹni nigba gbogbo.' Ṣiṣe ọrẹ pẹlu ete fojusun ohun ti wọn le fi silẹ laiṣe ohun ti wọn le gba.

B. ***Idanilọkanle***: Galatia 6:2 rọ awọn onigbagbọ lati maa ru ẹru ọmọnikeji wọn," o ṣatẹnumọ pataki idanilọkanle ninu ṣiṣe ọrẹ. Jijẹ ọrẹ gba wa niyanju lati maa ru ẹru ọmọnikeji wa, eyi ti yoo fun wa ni atilẹyin ati idanilọkanle. Ohun ti o jẹ otitọ ni pe, awọn ọrẹ maa n gbe ara wọn soke, wọn maa n ṣe atilẹyin, wọn si n ṣe koriya lasiko iṣẹgun ati ipọnju. Jijẹ ọrẹ ti o da le ete kan pato yoo sọ fun ọ ti o ba n ṣe aṣiṣe ni aye.

D. Iṣolotiitọ ati Iṣiro: Owe 27:6 jẹ ki a mọ pe a le gbẹkẹle ọgbẹ́ lati ọdọ ọrẹ, o ṣe atẹnumọ iṣolotiitọ ati iṣiro ninu jijẹ ọrẹ ti o da le ete. Jijẹ ọrẹ ti o da le ete pe fun ibara-ẹni-sọrọ tootọ ati biba ara ẹni ṣiro, fifi aaye gba ariwisi ati gbigba imọran gidi ninu idagbasoke ara-ẹni.

NINI ỌRẸ ATI GBIGBE JIJẸ ỌRẸ TI O DA LE ETE RÓ

Owe 27:17 ṣafiwe irin ti o n pọ́n irin pẹlu ipa ẹnikan si ẹlomiran. Ẹ ṣawari ọrọ idagbasoke ati ilọsiwaju ninu jijẹ ọrẹ ti o da le ete kan pato. Jijẹ ọrẹ ti o da le ete ni i ṣe pẹlu idagbasoke ati ilọsiwaju, pẹlu atẹnumọ lori pataki ifọwọsowọpọ ati pinpin iriri papọ. Iwe Oniwaasu 4:9-10 tẹsiwaju lati ṣatilẹyin pe ẹni meji san ju ẹnikan lọ, eyi n ṣatẹnumọ ifọwọsowọpọ ati imunadoko jijẹ ọrẹ.

Akiyesi: Ẹ jiroro nipa ipa ti ifọwọsowọpọ ati ibara-ẹni-kẹgbẹpọ ni lati mu erongba kan naa ṣẹ.

IPA TI JIJẸ ỌRẸ TI O DA LE ETE NI LORI IDAGBASOKE ẸMI

Owe 27:17 ṣatẹnumọ bi ẹnikan ṣe le pọ́n ẹlomiran, o n ṣatẹnumọ idagbasoke ẹmi ti jijẹ ọrẹ ti o da le ete n fi han. Nipasẹ iriri ti a ba pin, adura ati idanilọkanle, jijẹ ọrẹ ti o da le ete yoo di irinṣẹ lati mu idagbasoke ati idagba ti ẹmi wa.

AWỌN OHUN TI O ṢE PATAKI JULỌ NINU JIJẸ ỌRẸ TI O DA LE ETE

1. **Igbẹkẹle:** Ipilẹ jijẹ ọrẹ ti o le pẹ ni igbẹkẹle. Gẹgẹ bi Abrahamu ṣe ni igbẹkẹle patapata ninu Ọlọrun (Heberu 11:6; Jakọbu 2:23), ki a gbagbọ ninu eniyan jẹ atilẹyin fun igbẹkẹle. Igbẹkẹle maa n wa lori idaniloju pe ẹlomiran ni ifẹ rere rẹ ni ọkan. Laisi igbẹkẹle, ọrẹ le bajẹ, gẹgẹ bi a ṣe ri i ninu bi Judasi Iskariotu ṣe da Jesu Kristi (Orin Dafidi 41:6; Matiu 26:50).
2. **Otitọ:** Ọrẹ ti yoo pẹ ni ipilẹ ninu ododo ati iṣolotiitọ (Orin Dafidi 24:1-2; Johanu 14:6; 17:17; Efesu 4:25). Irọ pipa le ba ọrẹ jẹ, nigba ti iṣododo si n fun jijẹ ọrẹ lokun. Awọn ọrẹ tootọ maa n pin otitọ, koda ati igba ti o ṣoro tabi ti ko rọrun (Owe 27:5-6).
3. **Akoko:** Nini ibara-ẹni-ṣọrẹ ti o jinlẹ, ti o si duro pe fun akoko (Orin Dafidi 27:14). Igbẹkẹle, tii ṣe okuta igun ile ati jẹ ọrẹ ti yoo pẹ maa n waye bi ọjọ ṣe n gori ọjọ. Awọn ọrẹ kan maa n parẹ nitori pe wọn ko fi akoko silẹ lati mu un dagba, boya nitori ọna ti o jin sira wọn, iku tabi aini suuru. Ọmọwe Halpin sọ pe, 'Awọn eniyan ti o le mọ wa ti wọn fẹran rẹ, ṣugbọn ti o ko ba lo akoko daradara pẹlu wọn, akoko iwọ nikan pẹlu wọn, ẹ ko ni kuro nibi jijẹ ọrẹ ti o n ni aṣepọ lẹẹkọọkan lọ sibi jijẹ ọrẹ ti o ni itumọ.'

AWỌN KOKO PATAKI FUN JIJẸ ỌRẸ TI O DA LE ETE KAN PATO

Awọn koko mẹta pataki wa ki jijẹ ọrẹ ti o da le ete to le duro. Lara wọn ni:

1. ***Ibara-ẹni-sọrọ***: Awọn ọrẹ maa n ba ara wọn sọrọ ni gbangba, wọn a sọ aṣiri ati otitọ ninu ifẹ (Amosi 3:7; Owe 27:5-6, 17). Bakan naa, Ọlọrun fẹ ki a maa sọrọ lojoojumọ pẹlu Rẹ nipasẹ adura, O si n ba wa sọrọ nipasẹ ọrọ Rẹ ati Ẹmi Mimọ (Orin Dafidi 62:11; Johanu 10:27; Kọrinti Kinni 12:7-11).
2. ***Ibara-ẹni-kẹgbẹpọ***: Awọn ọrẹ maa n gbadun biba ara wọn kẹgbẹ pọ, wọn si maa n ṣe nnkan papọ (Jẹnẹsisi 2:18; Orin Dafidi 42:1-2, 7; Iṣe Awọn Apọsteli 2:44). Wọn mọriri akoko ti wọn ba lo papọ, ti o fi asopọ ibakẹgbẹpọ ti o tayọ akoko lasan han.
3. ***Ibikita ati Ikaanu***: Awọn ọrẹ tootọ maa n ṣafihan ifẹ, ibikita, ati ikaanu si ara ẹni (Johanu 4:7-8). Wọn maa n duro ti ara wọn lasiko ti o wọ̀ ati asiko ti ko wọ̀, wọn a jọ ṣalabapin akoko ayọ ati ibanujẹ (Luku 22:28; Roomu 12:15; Timotiu Keji 2:12). Ọrẹ tootọ maa n duro lori atilẹyin ati oye, ati lila igbesi aye kọja papọ.

AWỌN IPENIJA NINU IBARA-ẸNI-ṢỌRẸ TI O DA LE ETE KAN PATO

1. **Ipenija Akoko:** Iṣẹ maa n di wọn lọwọ, ifarajin lẹnu iṣẹ ati ojuṣe ara-ẹni le dena akoko ti awọn ọrẹ ni lati lo papọ, sọrọ, tabi ṣe nnkan papọ.
2. **Ọna Jinjin Sira Wọn:** Ọna ti o jìn si ara wọn, paapaa bi ọrẹ mejeeji ko ba gbe ni ibi ti o sunmọ ara wọn, o le jẹ ipenija lati maa ba ara wọn ṣe loorekoore, lati pin iriri wọn, ati lati maa dí aaye ibẹ̀ fun ara wọn lasiko ti o ṣe pataki si wọn.
3. **Idena Biba Ara-ẹni Sọrọ:** Iyatọ ninu ilana ti a fi n ba ara-ẹni sọrọ. Awọn nnkan ti o jẹ wa logun, tabi bi a ṣe ri aaye si le yọri si ede-aiyede, aisi idaniloju, tabi ki o dabi pe wọn ti yọ wa kuro ninu asopọ naa.

Scanned with CamScanner

4. **Awọn Ohun ti a Fẹran lati Ṣe le ma Ba ara wọn Mu:** Bi eniyan ṣe n dagba ti o si n yipada tabi lọ siwaju, ohun ti wọn fẹran, ifẹ ọkan wọn ati ohun ti o ṣe iyebiye si wọn, le yori si gbolohun asọ aijọra-wọn, ireti wọn le ma jọ ara wọn.

5. **Awọn Ipenija ninu Imọlara:** Fifi ara da igbòkè gbodò ile aye, yiyanju ọrọ aarẹ ọkan, tabi mimojuto imọlara ẹni nigba miiran le nipa lori oore-ọfẹ lati jẹ ọrẹ tabi ṣe atilẹyin fun ara-ẹni.

6. **Ireti ti Ko Papọ:** Iyatọ ninu awọn ohun ti a n reti nipa ijinlẹ jijẹ ọrẹ wa, bi a ṣe n beere ara wa, tabi ipo atilẹyin ti a ṣe le mu wahala tabi ede-aiyede wa.

7. **Awọn Ohun ti O n Ṣakoba lati Ode:** Awọn koko kan lati ode bii ohun ti n ṣele ni aarin ilu, aṣa ti o yatọ si ara wọn, ikẹgbẹpọ, tabi awọn ohun ti o ṣe iyebiye si idile kọọkan nigba miiran le ko ba awọn ohun ti jijẹ ọrẹ ti o ni ete da le lori.

BIBORI AWỌN IPENIJA NINU JIJẸ ỌRẸ TI O DA LE ETE

Didojukọ awọn ipenija wọnyi pe fun:

i. Ibara-ẹni sọrọ ni gbangba ati sisọ okodoro ọrọ funra ẹni
ii. Igbọra-ẹni ye
iii. Gbigba ti ara-ẹni rò
iv. Ikaanu ati
v. Ṣiṣetan lati gba ayipada ti o ba wa.

Matiu 18:15 sọrọ nipa ede-aiyede ati idarijin, o lo ẹkọ Bibeli gẹgẹ bi idari. O fun wa ni ilana idari nipa bi a ṣe le yanju ede-aiyede laarin awọn ọrẹ, o rọ ẹni kọọkan lati yanju ede-aiyede ni ikọkọ, ati pe ki wọn laja laarin ara wọn. Kolose 3:13 gba wa niyanju lati darijin, gẹgẹ bi abala ti o ṣe pataki lati ni ibara-ẹni-ṣọrẹ ti o da le ete, o ṣe tẹnumọ ojuṣe rẹ lati le jẹ ki ibara-ẹni-ṣọrẹ ti o ni itumọ wa bi o tilẹ jẹ a ko le yọ awọn ipenija ti yoo wa ṣẹyin.

ỌRỌ IPARI

Ibara-ẹni-ṣọrẹ ti o da le ete, gẹgẹ bi a ṣe ri i nipasẹ ẹkọ Bibeli, ṣatẹnumọ ifẹ, idanilọkanle, iṣotitọ, ati ṣiṣe atilẹyin funra ẹni. Nipa lilo awọn ilana wọnyi, eniyan le ni ibara-ẹni-ṣọrẹ ti o nitumọ ti kii ṣe pe o kan le dojukọ awọn ipenija lasan, ṣugbọn ti o tun le mu idagbasoke ẹmi ati alaafia wa. Ibara-ẹni-ṣọrẹ ti o da le ete kun fun ọgbọn ti Bibeli, o tayọ oye ibakẹgbẹpọ lasan. O jẹ asopọ mímọ́ ti ifẹ so pọ, idanilọkanle, iṣododo ati iṣiro. Gẹgẹ bi ẹni kọọkan ba ṣe n wa ijinlẹ ẹkunrẹrẹ jijẹ ọrẹ ti o nitumọ, kii ṣe pe wọn n wa asopọ ti o ni ifarada lasan, ṣugbọn wọn tun dawọle irin-ajo atunṣe si idagbasoke ti ẹmi ati alaafia. Ninu aye ti wọn ti n wa ijinlẹ ati ifidimulẹ, ẹkọ Bibeli yii duro bii imisi ti o n dari wa nipa jijẹ ọrẹ ti yoo duro ni akoko idanwo. Ọrẹ ti o ni itumọ yoo duro lẹgbẹ rẹ laiṣe asiko ti o dun nikan, ṣugbọn lati tun ṣe atilẹyin ati koriya fun ọ bi o ṣe n sa ere ije ti Ọlọrun fi siwaju rẹ.

AWỌN IWE ITỌKASI

- Rubin, K. H. (2002). *The friendship factor*. New York: Viking.
- Allan, G. *Kinship and Friendship in Modern Britain*. Oxford University Press 1996: Oxford.
- Spencer, L & Pahl, R. *Rethinking Friendship: Hidden Solidarities Today*. Princeton University Press 2006: New Jersey.

Scanned with CamScanner

ẸKỌ B

AWỌN KOKO TI A LE TẸLE NIPA AWỌN ILANA IDOKOWO

Idokowo ni kiko ohun-ini wa jọ lati fi ṣiṣẹ ni ireti ati gba nnkan nibẹ ni ọjọ iwaju. Ilana idokowo ti o dara maa n din ewu ku, ṣugbọn o maa n ṣamulo ohun ti o ṣe e ṣe ki a ri gba pada nibẹ. Pẹlu ilana tabi laisi ilana, o ṣe pataki lati ṣakiyesi pe ko si ẹni ti o padanu owo ti o ba dokowo sinu ọja ti aabo wa fun, bii rira ipin idokowo ati fifi owo dokowo. Ilana idokowo ti o dara saba maa n gba akoko ki o to ṣiṣẹ, a ko si gbọdọ ka a kun "ọna ati lowo kiakia." O ṣe pataki lati bẹrẹ sii dokowo pẹlu ireti ohun ti o ṣe e ṣe, laiṣe ohun ti a ko le gbe ṣe.

Idokowo ko ni gbedeke tabi ààlà, oludokowo tuntun ni ọpọlọpọ nnkan lati kọ́ lati le mọ bi yoo ṣe maa yara ṣe e. Ohun ti o jẹ iroyin ayọ ni pe awọn ti n ṣẹṣẹ bẹrẹ idokowo lẹ jẹ ki idokowo rọrun pẹlu awọn igbesẹ keekeeke kan, nigba ti wọn yoo fi awọn ohun ti o le tabi ṣoro silẹ fun awọn akọṣẹmọṣẹ.

Awọn Anfaani:

- Ki wọn pese silẹ fun owo ọjọ iwaju
- Kiko ọrọ̀ jọ́
- Lati bori lilọ soke owó ọjà
- Lati maa wa ọna ati ri owó keekeeke
- O funni ni ominira nipa ọrọ owó níná ati ifọkanbalẹ.

Bi a ṣe le ni Apo/Akojọpọ Idokowo: Lati ni idokowo ti yoo pẹ titi aye, ṣe awọn nnkan wọnyi:

- Dokowo sinu ara rẹ. Bawo?
    - Jẹ ki ẹkọ iwe jẹ ọ logun.
    - Kọ iṣẹ tuntun.
    - Gbe igbesi aye alaafia.
- Idokowo sinu rira Ilẹ tabi Ile ati Tita Ilẹ tabi Ile. Eyi pe fun owo gidigidi ṣugbọn ohun ti yoo mu wọle dara pupọ.
- Ọja ati Iṣẹ Agbẹ: Eyi ni i ṣe pẹlu rira ọja pamọ eyi ti owo rẹ yoo lọ soke nigba ti o ba ya.
- Rira ipin idokowo.
- Ṣiṣe iṣẹ paṣipaarọ owo ilẹ okeere.
- Owo tuntun crytocurrency (idokowo lori ayelujara)

- Bitcoin

Awọn Ofin ati Ilana:

- ✓ Iyapa: Nínawọ́jà idokowo ẹni si oriṣiriṣi ọna
- ✓ Ṣiṣe akoso ewu lẹnu oko owo, fifarada ewu ti o ba wa
- ✓ Erongba tabi afojusun ọlọjọ gbọọrọ tabi ọjọ pipẹ
- ✓ Iwadii ati ṣiṣe ohun ti o yẹ
- ✓ Ikora-ẹni-nijanu ninu imọlara: ni abala ti o dara ati eyi ti ko dara.

Ojuṣe ti O Jẹ Dandan Funra Ẹni tabi Ikora-ẹni-nijanu

- Ọlọrun ni akọkọ
- Ẹ ṣe iwadii ti o yẹ. Ẹ wadii awọn ohun ti o ṣe pataki ti o ṣe koko. Iwadii
- Ẹ ni afojusun tabi ilepa ti o han gbangba: ẹ ṣakoso imọlara yin, ki ẹ si tẹle ofin.
- Ẹ gbagbọ ninu idokowo naa pe yoo ṣiṣẹ; ẹ ni ọkan rere pe o le ṣe e ṣe.
- Ẹ maa kọ ẹkọ loorekoore, ki ẹ si maa ṣe atunṣe.

Awọn nnkan ti eniyan le ṣe nigba ti oko-owo ko ba lọ bi ẹ ṣe ṣeto rẹ:

- Ẹ yago fun yiyara ṣe ipinnu.
- Ẹ ṣayẹwo ohun ti o n ṣẹlẹ, ẹ kọ ẹkọ ninu aṣiṣe.
- Ẹ gba ojuṣe fun aṣiṣe yin.
- Ẹ ni ọkan ti o dara, ẹ maṣe juwọ silẹ.
- Ẹ tun eto ati ilana yin ṣe, ki ẹ si faaye gba anfaani tuntun.
- Ẹ ni afojusun, ki ẹ si maa tẹsiwaju lati gbadura.

Shalom!!!

Scanned with CamScanner

ỌJỌ ẸTI

ETO: IṢẸ-IRANṢẸ/IṢẸ IHINRERE

Abẹwo si Ibudo Ìfiniwọ̀/Ọgba Ẹwọn/Ere Oriṣiriṣi/ Afihan Iṣẹ-ọwọ tabi Iṣẹ Ọnà

ỌJỌ ABAMẸTA

ETO: APEJỌPỌ AJUMỌṢE

DIDE! TAN IMỌLẸ!

Isaiah 60:1-5; 61:1-4

Ọrọ Iṣaaju

Ki a to dawọlẹ ilana kankan lati sọ ohunkohun di òhun, yoo ṣe iranwọ lati ni idaniloju pe iru nnkan naa le ṣe e ṣe. Gbolohun ti o bẹrẹ ẹsẹ Bibeli ti o wa loke yii jẹ aṣẹ ti o fi ohun ti a gbọdọ ṣe han lẹyin ti a ti gba Kristi gẹgẹ bi Olugbala ati Oluwa. Loju ẹsẹ ti Kristi ba ti n gbe inu wa, a o di ẹni ti n fi imọlẹ han. Nipa mimẹnuba "imọlẹ ninu okunkun," ko tọkasi pe ile aye ṣokunkun. Aye ti o ṣokunkun nibi n tọkasi eniyan; ti o tumọ si pe a n ri okunkun ninu iṣe awọn eniyan, awọn ti ko ni imọlẹ. Idi niyi ti o fi jẹ pe ninu akọsilẹ Giriki, ọrọ yii "aye" ni itumọ meji niwọn igba ti o jẹ pe lati inu ọrọ Giriki meji ni wọn ti tumọ rẹ.

- Kosmos – ti o tumọ si awọn (eniyan) ti n gbe ile aye.
- Aions – tọkasi awọn iṣe tabi akoko.

Nigba ti ọrọ yii "kosmos" sọrọ nipa eniyan (awọn olugbe) ile aye, ọrọ yii "ainos" sọrọ nipa ọjọ ori yii, eyi ti o tumọ si awọn iṣe akoko yii ti o lodi si Ọlọrun tabi ọrọ Ọlọrun. Nitori naa, nipa sisọ pe "imọlẹ ninu okunkun aye," a n tọkasi "kosmos" iyẹn eniyan kii ṣe ile aye. Ṣugbọn sa, ki eniyan to le wa ninu okunkun, a jẹ pe awọn iṣe rẹ (ainos) ni yoo fi nnkan naa han. Ẹ ranti pe, ilo ọrọ yii "omi" ati "okun" ninu Jẹnẹsisi 1:2 ati Isaiah 60:5 n tọkasi eniyan. Fun idi eyi, nigba ti Isaiah sọ ni ẹsẹ 5 ori 60 pe " a o si yi ọrọ okun pada si ọ," o n tọkasi awọn eniyan, kii ṣe okun bi wọn ṣe lo o lọrọ lasan. A ko le yi okun ti a n fojuri pada, idi niyi ti o fi jẹ pe gbolohun ti o tẹle e sọ pe "ipa awọn Keferi yoo wa sọrọ rẹ." Awọn Keferi n tọkasi awọn eniyan, nitori naa, ilo okun nibi jẹ apejuwe awọn eniyan. Tori naa, Isaiah ninu ibi itọkasi wa gboogi n sọrọ nipa igbala.

Nitori naa, aṣẹ ti o sọ pe, "Ẹ jẹ ki imọlẹ wa" tabi "Dide tan Imọlẹ, nitori ti imọlẹ rẹ de" n tọkasi igbala. Igbala ni imọlẹ ti n tan lati inu okunkun. Eyi ni Kristi ti n gbe inu wa, ti o yi ipo wa pada kuro ninu okunkun (iwa ẹṣẹ) si Imọlẹ (igbala). Nitori naa,

nigba ti a ba di atunbi a ko tan lati jẹ imọlẹ; a n tan nitori pe a jẹ ẹni ti o ni imọlẹ Ọlọrun laye wa. Ogo ni fun Ọlọrun! Jẹ ki ọrọ Ọlọrun jẹ aṣẹ ti o kẹyin ninu aye rẹ.

Eleyii wa lati ṣi oju wa si otitọ pe a gbọdọ gba imọlẹ ologo laaye lati tan daadaa ninu ati ni agbegbe aye wa, ki a le ni ominira, ki a si tu wa silẹ kuro ninu igbekun okunkun aye. Fun idi eyi, o jẹ ipe itaniji fun awọn ọdọ Ajọ-nla Ijọ Onitẹbọmi Naijiria ni iran yii lati duro giri, ki wọn si ya ara wọn sọtọ kuro ninu odiwọn ti aye.

Ọrọ yii 'DIDE' ati 'TAN' ninu Isaiah 60:1 duro fun ayipada nitori pe a n tọkasi ayipada naa bi nnkan ti o dara. Mejeeji duro fun iwa mimọ ati ilọsiwaju ninu odiwọn ile aye, paapaa ni ibamu pẹlu eto Ọlọrun gẹgẹ bi a ṣe fi han nipasẹ Wolii Jeremiah (Jeremiah 29:11) ati Apọsteli Pọọlu (Johanu Kẹta 2): "*Nitori emi mọ iro ti mo ro si yin, ni Oluwa wi, ani iro alaafia, kii si i ṣe fun ibi, lati fun yin ni igba ikẹyin ati ireti.*" (Jeremiah 29:11); "*Olufẹ, Emi n gbadura pe ninu ohun gbogbo ki o le maa dara fun ọ, ki o si maa wa ni ilera, ani bi o ti dara fun ọkan rẹ*" (Johanu Kẹta 3:2).

Nitori bi nnkan ṣe bajẹ ni aye wa yii ti irẹwẹsi wa, ti o si ri júujùu, Isaiah n kede ọpọlọpọ awọn ibukun ti yoo wa fun awọn ọkan onirobinujẹ ati ọkan ironupiwada ati ọkan irẹlẹ, ti o si gbọran si Ọlọrun nipa titẹle ofin Rẹ. Ipa ti o ni ni pe, bi o ti wu ki ipo ti ri ni atijọ tabi akoko yii, nigba ti Ọlọrun ba farahan, ti a si tẹwọgba A, o daju pe a o ni iriri sisun siwaju ninu aye wa. ***Njẹ ibaṣepọ tabi igbeyawo rẹ polúkúmuṣu? Njẹ ọrọ ajé rẹ n kuna? Njẹ igbesi aye ẹmi rẹ n fa sẹyin? Njẹ o n dojukọ okunkun ninu iṣẹ ayanlaayo rẹ, pẹlu ọrọ ọmọ rẹ tabi ilepa ọrọ ẹkọ rẹ?*** O si le dide, ki o tan imọlẹ. Bẹẹni o le ṣe bẹẹ. Pẹlu Ọlọrun, ohun gbogbo ni ṣiṣe (Matiu 19:26). Halleluyah!

Awẹ ọrọ yii DIDE, TAN kii ṣe ohun ti a fun wa gẹgẹ bi imọran. Kii ṣe àbá tabi àlá, bẹẹni kii ṣe ero lasan. O jẹ aṣẹ ti a gba lati ọdọ Ọlọrun. Nigba ti aṣẹ ba wa lati ọdọ Ọlọrun, o maa n pé. Gẹgẹ bi Orin Dafidi 19:7 ṣe sọ: "Ofin OLUWA pe, o n yi ọkan pada: ẹri OLUWA dani loju, o n sọ ope di ọlọgbọn." Ohunkohun ti Ọrọ Ọlọrun ba sọ ti yanju, ani ni ọrun (Orin Dafidi 119:89): "Oluwa, lai, ọrọ rẹ kalẹ ni ọrun." Ọlọrun ti sọ Ọrọ Rẹ pe ki a dide tan imọlẹ. A gbọdọ ni iwa rere lati yipada kuro ni ipo ti a wa lọwọlọwọ bayii. Eṣu ko le yipada tabi yi eto Ọlọrun pada fun wa ti a ba fọwọsowọpọ pẹlu Ọlọrun nitori pe O jẹ ẹni mimọ ati olotiitọ si ọrọ Rẹ. Dide, tan imọlẹ!

"***Dide***" jẹ ipe fun awọn onigbagbọ lati duro tiiri; ki wọn yago fun ati maa rin pẹlu aye. Iṣẹ wa ni aye ko faaye gba ẹṣẹ. A ni lati maa gbe pẹlu idari Ọlọrun fun ogo ijọba Rẹ. Aye le maa beere pe ki a gbe gẹgẹ bii tiwọn, ṣugbọn a gbọdọ kọ̀, ki a si wa ni iha ti Ọlọrun. A gbọdọ jade sita kuro ninu aye, ki a si maa gbe pẹlu odiwọn ti Ọlọrun. A

Scanned with CamScanner

ni lati dide kuro ninu àgàbàgebè aye, ki a jẹ ajigbèsè fun ogo ijọba Ọlọrun ati pe ki a maa lepa ogo ijọba Ọlọrun.

Ọrọ yii "***Tan***" sọrọ nipa bi Ọlọrun ṣe tan oore-ọfẹ ati otitọ Rẹ sita ninu aye wa nipasẹ Kristi Jesu. Ko dara to ti a ba kan dide, a tun gbọdọ tan pẹlu. Ọna kan ti a fi le tan imọlẹ ni nipa titete kọkọ wa Ijọba Ọlọrun na ṣaaju ohun gbogbo. Dipo lilepa okiki ati ọrọ, o ṣe pataki fun wa lati mu ihinrere lọ sinu aye nipa jijẹ apẹrẹ rẹ ninu ọrọ ati iṣe wa. A gbọdọ kọ lati jọ inu iṣura wa ki a to ju wọn nu, ati ki a to juwọ silẹ ninu iṣẹ ti Ọlọrun ya wa sọtọ fun.

Bibeli wi pe, "*Ẹyin ni imọlẹ aye. Ilu ti a tẹdo si ori oke ko le farasin. Bẹẹni a kii tan fitila tan, ki a si fi i sabẹ osuwọn; bikoṣe lori ọpa fitila, a si fi imọlẹ fun gbogbo ẹni ti n bẹ ninu ile. Ẹ jẹ ki imọlẹ yin ki o mọlẹ to bẹẹ niwaju eniyan, ki wọn ki o le maa ri iṣẹ rere yin, ki wọn ki o le maa yin Baba yin ti n bẹ ni ọrun logo.*" (Matiu 5:14-16).

Ṣiṣalaye Aṣẹ Wa (Isaiah 60:1b). Alaye ati agbara iṣẹ ihinrere wa n wa bi a ṣe n ranti orisun ti a ti gba imọlẹ wa, ti okunkun ko si da wa laamu, a ni lati dide, ki a jẹ ki imọlẹ Ọlọrun tan sinu aye wa. Nigba naa ni imọlẹ le tan sinu okunkun, ti a le bori rukerudo, ti àgbóyé yoo si jọba lori idaamu. A o maa fojusun ọrun debi pe a o gbọ ohùn Oluwa ketekete.

Ọrọ naa si di ara, Oun si n ba wa gbe, awa si n wo ogo Rẹ, ogo bii ti ọmọ bibi kanṣoṣo lati ọdọ Baba wa, O kun fun oore-ọfẹ ati otitọ. (*Johanu 1:14*).

"Kii ṣe nipa iṣẹ, ki ẹnikẹni ma baa ṣogo. Nitori awa ni iṣẹ ọwọ rẹ ti a ti da ninu Kristi Jesu fun iṣẹ rere, ti Ọlọrun ti pese tẹlẹ, ki awa ki o le maa rin ninu wọn." (*Efesu 2:9-10*)

Ipe wa ni lati tubọ mọ gidi sii nipa Kristi ati imọlẹ ologo Rẹ. Oun ni ireti wa. Ninu Kristi imọlẹ aye, a o ri ogo Ọlọrun. A gbọdọ tẹra mọ ọn lati mọ Kristi siwaju ati siwaju sii nitori pe a ko jẹ nnkan kan laisi Kristi.

Agbara Atunṣe Imọlẹ: *Dide, tan imọlẹ; nitori ti imọlẹ rẹ de, ogo Oluwa si yọ lara rẹ. "Nitori kiyesi o, okunkun bo aye mọlẹ, ati okunkun biribiri bo awọn eniyan; ṣugbọn Oluwa yoo yọ lara rẹ, a o si ri ogo lara rẹ"* (*Isaiah 60:1-2*).

Gbigbe niwaju Ọlọrun maa n yi aye eniyan pada. A bi wa sinu aye ti o kun fun okunkun. Okunkun naa jinlẹ debi pe a ko le ri ọna kuro ninu rẹ. Ṣugbọn nipa oore-ọfẹ, a gba wa la. Ogo Ọlọrun dide sori wa gẹgẹ bi oorun ti n yọ loju ọrun. Bayii a wa ri i bi a ṣe da ohun gbogbo fun ogo Rẹ. Gẹgẹ bi onigbagbọ, a ko gbọdọ maa wa

idanimọ, ete tabi agbara lati ọdọ awọn nnkan ti o wa yi wa ka. A ni lati tan Imọlẹ si awọn ti wọn wa yi wa ka, ati awọn ti o jinna ati awọn ti o wa ninu okunkun biribiri. Nitori naa, a gbọdọ mu erongba wa lọkunkundun lati jẹ ki imọlẹ Ọlọrun tan nipasẹ wa.

"Ninu rẹ ni iye wa; iye naa si ni imọlẹ araye. Imọlẹ naa si n mọlẹ ninu okunkun, okunkun naa ko si bori rẹ" (*Johanu 1:4-5*).

Ọlọrun pinnu iru ọna ti yoo gba mu okunkun naa kuro. O le fi imọlẹ Rẹ han, ki o si ya gbogbo eniyan lẹnu. Dipo bẹẹ, Oluwa yan lati jẹ ki imọlẹ Rẹ tan nipasẹ ohun-elo ti o gba A gẹgẹ bi imọlẹ ninu aye wọn, wọn si di ẹni ti n ru imọlẹ Rẹ kiri. Nipasẹ wọn, imọlẹ Ọlọrun yoo si tan si gbogbo agbaye.

Nigba ti aye wa ba gba atunṣe, o le ran awọn eniyan miiran lọwọ lati mu ilọsiwaju ba aye wọn, ati pe awọn ti wọn wa lagbegbe wa yoo ri iṣẹ iyanu Ẹmi Ọlọrun ninu wa. Awọn orilẹ-ede wa sinu imọlẹ, ti i ṣe imọlẹ Ọlọrun ninu wa. Gẹgẹ bi onigbagbọ, afojusun wa gbọdọ wa ninu gbigbe igbesi aye ododo nibikibi ti a ba lọ. Gẹgẹ bi imọlẹ Ọlọrun ṣe n tan nipasẹ aye wa, bẹẹ naa ni wọn yoo si ṣe wa si imọlẹ.

Awọn nnkan ti o duro bi idena wa lati di wa lọwọ lati fi imọlẹ Ọlọrun han. Awọn nnkan naa ni ọgbọn eniyan, oye ati iriri wa. A mu wọn lọkunkundun pupọ pupọ debi pe, laimọ, a maa n fi wọn rọpo agbara iwaalaye Ọlọrun Olodumare. A ni lati ṣọra.

Ọrọ Ipari

O ṣe pataki fun wa gẹgẹ bi onigbagbọ lati ni ibaṣepọ timọtimọ pẹlu Ọlọrun, ki a si yago fun ẹṣẹ. Bi a ba ṣe sunmọ Ọlọrun si, bẹẹ ni ayọ ati alaafia ti a o ni. Ni kukuru, bẹẹ ni a o ṣe bukun fun igbesi aye wa si. Ni odikeji, bi a ba ṣe sunmọ ẹyin kuro lọdọ Ọlọrun si, bẹẹ ni ayọ ati alaafia ti a o ni yoo ṣe kere to, bẹẹni a o si tubọ maa jinlẹ sii ninu ẹṣẹ. Nitori naa, ojurere Oluwa tumọ si pe a ni ọna abayọ nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa.

Njẹ o wa ni ọdun riri ojurere lọdọ Oluwa? Njẹ Ọlọrun bukun fun aye rẹ? Tabi ṣe o lero pe ohun gbogbo ni o n tako ọ, o ko ni ayọ tabi alaafia? Gba adura yii:

- Baba wa ọrun, Ẹ tu Ẹmi yin sori wa, Ẹ dari wa lọ sinu imọlẹ ati otitọ ọrọ Yin ninu Kristi Jesu; nitori pe Ẹyin nikan ni o le dari wa lati seso ni ijọba Yin, ti a si le tan ninu imọlẹ iwalaaye Yin. Ẹ ṣe wa ni alayọ ati onidunnu lati jẹ iranṣẹ Yin, Ẹ bukun fun wa, ki ẹ si fi gbogbo akitiyan wa sinu ṣiṣe ohun ti Ẹ o fẹ ki a ṣe. Oluwa, Ẹ jẹ ki a le dide, ki a fi ogo Yin han, Ẹ si dari wa lati tan imọlẹ Yin ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

Scanned with CamScanner

ORIN ỌSẸ ỌDỌ

YBH 277
'GBA T'A B'OLUWA RIN

1. Gbat'a b'Oluwa rin
N'nu 'mọlẹ ọrọ Rẹ
Ọna wa yi o ti l'ogo to!
'Gbat'a ba n ṣe 'fẹ Rẹ
Oun y'o ma ba wa gbe
Ati awọn t'o gbẹkẹ wọn le

Egbe: Ṣa gbẹkẹle
Ọna miiran ko si
Lati l'ayọ n'nu Jesu,
Afi k'a gbẹkẹle.

2. Ko si ajaga mọ
Ko si 'banujẹ mọ
Gbogbo wahala wa ti pari
Ko si arokan mọ,
Tabi ifajuro,
Afi 'bukun t'a ba gbẹkẹle.

3. Awamaridi ni
Ayọ ifẹ nla Rẹ
Titi a o fi f'ara wa rubọ,
Aanu ti O n fi han,
At' ayọ t'O n fun ni
Jẹ ti awọn ti o gbẹkẹle.

4. Ni idapọ didun
L'ao joko l'ẹsẹ Rẹ
Tabi ki a ma rin pẹlu Rẹ,
Awa y'o gbọ ti Rẹ,
A o jiṣe to ran wa,
Maṣe bẹru ṣa gbẹkẹ rẹ le.

ỌBA AIKU, AIRI, ORISUN ỌGBỌN
(Immortal, Invisible, God Only Wise)

1. Ọba àìkú, àìrí, orisun ọgbọn
T'o wa ninu imọlẹ t'oju kole wo
Olubukun julọ, ologo julọ
Alagbara, Olusẹgun, 'Wọ la yin

2. Laisinmi, laiduro, ni idakẹjẹ
O n jọba lọ, o ko si ṣe alaini
Giga ni idajọ Rẹ bi oke nla
Ikuku Rẹ b'isun ire at' ifẹ

3. O n tẹ gbogbo ẹda alaye lọrun
Nipa imisi Rẹ wọn n gbe igbe wọn
A n dagba, a gbilẹ bi ewe igi
A si n rọ, ṣugbọn bakan naa l'Ọlọrun

4. Baba nla ologo, imọlẹ pipe
Awọn angẹli Rẹ wolẹ l'ẹsẹ Rẹ
Iyin wa la muwa, jọ ran wa lọwọ
K'ale r'ogo imọlẹ to yi Ọ ka

AWỌN ONKỌWE FUN ỌSẸ ỌDỌ

Isin Owurọ Ọjọ Isinmi :
Ẹni-ọwọ Joshua Sunday IBUKUNOLUWA
Alakoso awọn Ọdọ Gbogbo-gboo
Ajọ-nla Ijọ Onitẹbọmi Naijiria
Olu Ile Iṣẹ Ijọ Onitẹbọmi, Ibadan
0803 826 3958

Irọlẹ Ọjọ Isinmi – Ọrọ Ilera:
Dokita Emuesiri Goodies MOKE
Aarẹ, awọn Ọdọ Ajọ Ipinlẹ Ethiope Delta
Ẹka Pharmacology
Delta State University, Abraka, Nigeria
+234 706 104 0692
egmoke@delsu.edu.ng

Ọjọ Aje – Ẹkọ Bibeli:
Oniwaasu E. A. OLUṢHỌLA
Aarẹ, Awọn Ọdọ Ijọ Onitẹbọmi ti Ajọ-Ipinlẹ Kogi
+234 806 359 2242

Ọjọ Iṣegun – Adura:
Oniwaasu Michael IROKO
Alakoso Adura, NBCYC
+234 706 894 4498

Ọjọ 'Ru – Ere Ori Itage:
Iyaafin Janet Temitọpẹ BIOYE
Bridal Designer
Airport Baptist Church, Ibadan
+234 802 214 3431
temitopejanet63@gmail.com

Ọjọ 'Bọ – Ikọni A:
Oniwaasu Kẹhinde Daniel ADEṢINA
Oore-ọfẹ Baptist Church, Ado Ekiti
Akọwe, Awọn Ọdọ Ijọ Onitẹbọmi ti Ajọ Ipinlẹ Ekiti
+234 703 347 1972
biggenesis27@gmail.com

Ọjọ 'Bọ – Ikọni B:
Arakunrin Oluwatosin IDOWU
Software Engineer
Solid Rock Baptist Church, Oluwo
Ijọba Ibilẹ Ẹgbẹda, Ibadan
+234 909 434 8926

Ọjọ Abamẹta – Ipejọpọ:
Iyaafin Ochuko Destiny AZUBIKE (Nee Agbovwan)
Alaga, Awọn Ọdọ Ijọ Onitẹbọmi ti Ajọ Ipinlẹ South East
+234 7-3 690 4146

Iṣẹ Olootu waye lati Ọwọ:
Iyaafin Olubunmi Adigun
Olootu Agba/Eto/Oṣiṣẹ Olusakoso
Youth and Student Ministries
Baptist Building, Ibadan
0805 394 1791 tabi 0815 999 0026

Scanned with CamScanner